# Ìbátan Olùràpadà Náà

Jeffersonville, Indiana, USA

Ọjọ Keji, Oṣu Kẹwa, 1960

1 O ṣe, Arakunrin Neville, ki Oluwa ki o bukun ọ. O dara lati pada lẹẹkan sii lowurọ yii, lati pada si ile Oluwa. Mo gbagbọ pe a sọ ọ nigba kan wipe “Inu mi dun nigba ti wọn sọ fun mi pe, ẹ jẹ ki a lọ si ile Oluwa.”

Charlie, jade kuro lẹyin òpó yẹn ki o si ma a bọ ni oke nihin ki o gbe aga kan fun ara rẹ, ma a bọ loke nihin. Arabinrin.... Njẹ aga kan wa lẹyin lọhun nibi kan nibẹ ti a le fun mọ ibẹ? Aaye kan wa loke nihin ọdọbinrin. Ma a bọ loke taara nihin. Nihin, Charlie, ma a bọ nihin, joko lẹgbẹ Banks loke nihin ki o ma ba a ni lati nàró. Igba-kuu-gba ti ọmọkunrin naa ba wa lati isalẹ ni Kentucky lọhun, ti o ba wa sihin.... O ma a n nàró ni gbogbo owurọ ni. Nitori naa a o wa aaye fun loke nihin.

2 Aaye kan wa ni opin awọn aga nihin fun ẹlomiran (Ẹnikan sọrọ lati inu ijọ] Ọmọbinrin kan wa ti o dide duro lẹyin, lẹyin lọhun abi? Ma a bọ taara loke nihin. Aga kan wa ni tosi nihin, arabinrin, ti o sunmọ ihin, ma a bọ taara ni waju nihin. Mo si ro wipe ẹnikan wa lori aga-ijoko amukun nibẹ! Sẹ wọn wa nibẹ? Bẹẹ ni. Aga miran tun wa ni tosi nihin. Bi ẹnikan lẹyin ba n fẹ aga kan, ni tosi nihin aga wa nihin. Omiran tun niyi loke nihin pẹlu, ẹ saa tẹ ara yin tọrun. Bẹẹ ni, a ni aga kan nihin.

Wayi ẹ ma a bọ taara bẹyẹn, ẹ joko, ki ẹ si ni imọlara ti.... awa fẹ ki ara ki o tu u yin nigba ti a n gbiyanju lati mu Ọrọ Oluwa wa.

3 Oo, dajudaju o dara lati wa ni ihin! Emi ko i ti i ri Charlie ni ibi aga iwaasu. Njẹ o wa lẹyin lọhun bi? O da, ẹ ba wa fa a jade sita nihin. Mo ti wa pẹlu Charlie ni isalẹ lọhun fun awọn ọjọ diẹ bayi, emi ko si lee kọja lai ya ile rẹ ki n si jẹun, nitori naa, n o mu un wa taara si ibi ori pẹpẹ iwaasu ni owurọ yii. Ni ojoojumọ bi o ba wa sihin, o ma a n duro ti ogiri ni lati lee fun ẹnikan laaye lati joko. Nitori naa mo de ni owurọ yii, mo si ri i wipe o dide duro nibẹ ni. Emi wa ro o wipe, “Emi yoo mu un wa si ihin bayi.” O daa, o jẹ ohun kan.... Iyẹn dara o. Bayi, awa yoo gbọ iwaasu naa ni owurọ yi lati ọwọ Arakunrin Russel Cox [Arakunrin Branham bu si ẹrin] Awọn Nellie da? Iyẹn yoo jẹ gigun ẹsin ti o dara fun un niyẹn. Bẹẹ ni, bi o ṣe ri niyẹn.

4 O dara, dajudaju inu mi dun lati ri ọpọlọpọ awọn ọrẹ mi ti wọn jade. Ni ọjọ Aiku ti o kọja, nigba ti mo kuro, inu mi bajẹ fun odidi ọsẹ kan. Mo ni ọrẹ kan ti o dara, ti o wa lati isalẹ isalẹ Gusu naa ti o joko nihin, orukọ rẹ ni Arakunrin West, mo si ti lọ laarin gbogbo ijọ, mo pẹ ki n to de, mo si wipe, Inu mi dun lati ri lágbájá, ati lakaṣeṣe, oju mi si fo Arakunrin West, emi ko si kiyesii, titi ti o fi bẹrẹ si i jade. Mo si ronu lori eleyi ninu gbogbo ọsẹ naa pe, Arakunrin West yoo ro wipe mo mọọmọ fi oju foo oun ni. Ṣugbọn Kristẹni ni o jẹ, o mọ dara ju iyẹn lọ. O mọ wipe emi.... ọrẹ gidi ni o si jẹ. Mo si mọ wipe, o mọ pe emi ko lee ṣe bẹẹ.

5 Nigba ti mo n bọ ni owurọ yii, mo n ronu lati ri awọn eniyan ti wọn yoo wa lati oriṣiriṣi ibiti o yatọ si ra.... Wayi nihin ni Arakunrin West wa lẹyin lọhun lẹẹkan sii ni owurọ yii, ati Arakunrin aṭi Arabinrin Kidd nihin lati Ohio, ati awọn temi kan.... Mo mọ pe Arakunrin Evans wa nihin. Mo lọ lati rii ni ọ̀sán àná ni ile-itura naa, ṣugbọn mo ro wipe, o jade pẹlu Arakunrin Fred ati awọn iyooku wọn. Gbogbo wọn si maa n wa lati ọna jinjin lati Macon Georgia, si ihin ni gbogbo ọjọ Aiku ti mo ni lati waasu. Lati Macon, Georgia. Ọna ti o jin gan an ni o. Mo ro wipe, o to ibusọ igba-mẹrin tabi ju bẹẹ lọ, ni ọna jinjin lọhun. O n wakọ wa pẹlu ẹbi rẹ ni gbogbo ọjọ ti mo ba ni lati waasu. Eyi jẹ jijẹ olootọ si ni.

6 Mo si wa n ro o nigba naa pe, bi eniyan kan ba ni awọn ọrẹ bi iru awọn wọnyii ti wọn fẹ duro ti ni.... Wayi, awọn eniyan wọnyii ko wa lati ọna jinjin bi i lati Georgia ati Ohio, ati oriṣiriṣi abala awọn orilẹ-ede ti o yatọ sira wa si ago kekere nihin lati gbọ mi. Wọn n wa si ihin nitori pe wọn gbagbọ ninu Iṣẹ-iriju iwaasu naa. Ohun ti wọn gbagbọ niyẹn. Wọn gba Iṣẹ-iriju-Iwaasu naa gbọ. Nigba naa bawo ni o ṣe yẹ ki n jẹ olootọ inu ati olododo to ni iṣẹ-iriju-iwaasu naa. Nitori ki i ṣe ara mi nikan ni mo n mu lọ sinu ikuna, ṣugbọn mo n dari ẹlomiran lọ sinu ikuna, ẹ rii. Ọlọrun yoo si mu mi jiyin fun ikuna an wọn, nitori emi ni mo kọ wọn ni Ọrọ Ọlọrun naa, ẹ rii.

Mo sọ fun ọ, dajudaju eyi yoo mu ki o ronu jinlẹ nigba ti o ba n ronu ni ọna yẹn. Ṣugbọn, mo mọ riri olukuluku yin. O dara lati mọ wipe ẹ n wakọ laarin gbogbo ọpọlọpọ ọgọrun ibusọ ninu gbogbo ewu oju ọna ati ninu gbogbo awọn opopona ti wọn tayọ nibi ti awọn ijamba ọkọ ati gbogbo nnkan bẹẹ.... Igbagbọ yin ninu Ọlọrun ni o n mu un yin la gbogbo nnkan wọnyi kọja lọnakọna, ti o n mu yin wa si ihin ti o si n mu yin pada sile. Inu wa dun lati ni iru ẹyin ọrẹ bẹẹ. Mo si bẹbẹ fun awọn ibukun ti o ni ọrọ̀ ki o wa si ori i yin.

7 Wayi, ni ọjọ Aiku ti o kọja mo wipe “O dara, a o waasu, ati lẹyin naa emi yoo pe fun ila adura. Mo ti n gbiyanju lati gbe eto kan kalẹ ti yoo mu ki o ṣeeṣe fun mi lati gbadura fun awọn eniyan ti o pọju awọn ti mo ti n gbadura fun lọ ṣugbọn bi mo ba ṣe e ni igba pupọ bi mo ṣe ṣe e ni Ọjọ Aiku ti o kọja, ẹnikan yoo ma a gbadura fun emi pẹlu ni. Mo fi ibi yii silẹ bii aago meji oru. N ko si pin kaadi adura.

Fifun ni ni kaadi adura jẹ iṣẹ ti ko ni iwuri rara. Emi ko mọ boya ẹ mọ ọn tabi bẹẹ kọ, awọn eniyan yoo

saa korira rẹ ni. Ni ijeloo, Arakunrin Banks Wood sọ nigba ti a wa ni Kentucky pe oun yoo finufidọ jọwọ ara oun lati pin kaadi adura bi Billy ko ba wa. Nitori naa, “Billy, nitori pe o jẹ ọmọ temi, ẹ mọ, mo gba awọn lẹta kan pe, 'Billy ṣe ileri lati fun mi ni kaadi adura, ko si fun mi, ọmọ ti o jẹ eku kekere na a.” Nitori naa wọn.... Ko lee fun gbogbo eniyan ni kaadi adura. A ko si lee gba ero pupọ sinu ila adura. Ẹ rii, ọmọ naa ni lati da abo bo mi.

8 Nigba ti a si fi ibẹ silẹ, iyawo ọmọ mi sọ wipe, “Bill, o ni lati rii daju pe Billy pada si ori eto pinpin kaadi lai jẹ bẹ ẹ,” o wipe, “ẹmi rẹ ko ni gun rara.”

Ṣugbọn ibi ti mo ti ṣe aṣiṣe mi ni bibẹrẹ isin imọ-ọkan-yatọ. Lẹyin naa ẹnikan yoo pada yoo si sọ wipe, “Mo gbagbe, iya mi fẹ ki a gbadura fun oun.” Ṣe o mọ ohun ti wọn n pa dabọ wa fun, imọ-ọkan-yatọ naa ni, o rii. Ṣugbọn emi ko da wọn lẹbi. Emi pẹlu yoo ṣe bakan naa, ẹ rii. Emi yoo ṣe e.... Eniyan ni wa, gbogbo wa si ni a fẹ wa laaye, a si fẹ mọ ohun ti a ni lati ṣe. Ohun ti a wa pẹlu.... Ṣugbọn o ko le rin jinna pupọ pẹlu awọn nnkan wọnyẹn, o jẹ ẹbun kan, lẹyin naa okun rẹ yoo pari, nigba ti iyẹn ba ṣẹlẹ ni ọpọlọpọ igba.

Nitori naa, Arakunrin Banks fẹ pin kaadi adura laarọ yii, Billy si de ni alẹ ana. Mo wa ro o wipe eyi ko ni dara rara, lati fun ọkunrin kan ti o ni ọla pupọ ati awọn nnkan bi Arakunrin Woods ni iṣẹ ati ma a pin kaadi adura. Ki awọn eniyan wa maa ri i fin. Mo ro wipe nnkan bẹẹ ko lee dun Billy. O ti fi ara da iru nnkan bẹẹ fun igba pípẹ́, nitori naa ko ni binu. Yoo ni pe o ti dara.

9 Ni ọsẹ ti o n bọ yii, ni ọjọ Ẹti, emi n lọ si Dallas, nibi agọ-ajọ ti awọn Ohùn Ìwòsàn. Bi awọn kan yoo ba wa nibẹ, emi yoo wa nibẹ lati waasu ni alẹ ọjọ kan nibi agọ-ajọ wọn. Mo si fẹ sọrọ lori akori iwaasu “Ọna Lati lọ ninu Idapọ”, bi Oluwa ba fẹ.

Ati lẹyin naa, boya ni ọjọ Isimi ti o n bọ, bi Oluwa ba fẹ.... Wayi, eyi ko da mi loju daadaa. Bi Oluwa ba fẹ, mo fẹ́ pada wa ki n si waasu lori ẹkọ pataki ti o ti yẹ ki n waasu le lori loni ti i ṣe, “Afẹfẹ naa ninu Iji àjà-yíká. Mo si n fẹ gbadura fun awọn alaisan loni, iru iwaasu bẹẹ ti o jẹ ti ibawi ti o le si ijọ nitori awọn ẹṣẹ wọn, eyi ko jẹ ẹkọ iwaasu ti o dara pupọ lati sọrọ le lori nigba ti a ba fẹ pe fun adura fun awọn alaisan. O ni lati mu ki igbagbọ awọn eniyan lọ si oke si Ọlọrun, ki wọn lee ni igbagbọ. Nitori naa, mo sọ fun Arakunrin Neville ki o kede pe emi yoo waasu laarọ yii lori akori miran ti yoo ru igbagbọ awọn eniyan soke si Ọlọrun. Ti iwaasu akọkọ jẹ lati ba awọn eniyan wi fun wipe wọn ko pa awọn ofin Ọlọrun mọ. Ṣugbọn eyi jẹ riru igbagbọ awọn eniyan soke lati ni igbagbọ ninu Ọlọrun, ẹ rii.

10 Ati lẹẹkan ninu iyara adura ni owurọ yii, tabi ki n sọ wipe ninu iyara ti a ti n gba awọn iwaasu silẹ, lẹyin lọhun, ọrẹ mi baba arugbo kan, Arakunrin Kidd, o ti le ni ọgọrin ọdun.... ọgọrin ọdun ti o joko nihin. Ọpọlọpọ yin ranti igba ti mo n kanju lọ sọdọ rẹ ni owurọ ijelo, o ti n (o to bi ọdun kan sẹyin, bayi tabi ki o ma to bẹẹ), ku lọ, aisan naa buru jai, awọn dokita fun un ni ọsẹ kan lati wa laaye. Tabi, kii ṣe ọsẹ kan, wọn ni.... Ko le wa laaye di owurọ, ki a fi lee gbe e wa si ihin bi ọjọ mẹta ni ko fi mọ ibi ti o wa. Ṣugbọn bayi, mimi rẹ ti walẹ diẹ gan an, o ti wa lẹ. O ni oun ni imọlara pe ọmọkunrin kekere ni oun jẹ.

Arakunrin Kidd, mo n ro wipe iba dara bi ẹ ba lee dide duro ki awọn eniyan mọ ẹni ti baba arugbo oniwaasu yi si jẹ. Oun niyẹn o. Ẹ jẹ ki a sọ pe, “Ẹ ṣe Oluwa.” Ọkunrin kan ti o n ku lọ pẹlu arun jẹjẹrẹ, ni ipo naa. O ni iyawo kan ti o dara pupọ pẹlu rẹ nibẹ. Emi iba fẹ pe ki o dide duro pẹlu. Mo fẹ.... Arabinrin Kidd, iba dara bi ẹ ba le e dide duro ni ibi ti ẹ wa na a? Ẹ wo bi o ṣe lee yara dide duro to? O lee yara dide ju mi lọ. Ki Ọlọrun ki o bukun Arakunrin ati Arabinrin Kidd. Njẹ ki ibukun Ọlọrun ti o lọrọ pupọ simi le e wọn. Ẹ ṣe, arabinrin.

11 Wọn n la kaka la gbogbo awọn oke-nla ti Kentucky ja, wọn n lọ soke lọ sodo ni awọn ipa ọna ti awọn papa eedu, wọn n le wọn jade, wọn n ti wọn jade, wọn n fi wọn ṣe ẹlẹya, wọn n ṣe inunibini si wọn, wọn n jẹ ohunkohun ti wọn lee ri jẹ. Wọn n lọ agbado ti wọn ba ri ni oju ọna ni ibikibi, wọn si n gbe fun ijọba Ọlọrun.

Awọn ẹni ọgọrin ọdun ni wọn, wọn si n waasu ihinrere sibẹ. Bayi, wọn ti dagba pupọ ju lati ma a jade, nitori naa, emi n gbadura lori aṣọ pelebe pelebe, mo si n fi ranṣẹ si wọn, wọn si n mu awọn aṣọ adura wọnyi jade lọ si ile-iwosan ati ibi gbogbo bẹẹ. Awọn eniyan n wa, wọn n gba wọn. Wayi, eyi jẹ ohun ti o ṣe pataki lọkan ẹni, a bi bẹẹ kọ? Bi iwọ ko ba lee jade lọ ba wọn, o le e fi aṣọ adura ranṣẹ si wọn lọna naa, awọn eniyan wọnyi ni igbagbọ, iyẹn dara pupọ.

12 Arakunrin Rogers pẹlu ti wọle nibi kan pẹlu nihin loni, ẹni ti o jẹ Baba iyawo Arakunrin Creech. Ọrẹ mi ọwọn. Emi ma a n lọ si ile rẹ bi mo ṣe ma a n lọ si ile Charlie ati Nellie ati awọn iyooku wọn ni isalẹ nibẹ lọhun, ati lọhun ni Kentucky. Mo ma a n lọ si ibẹ tẹlẹ lati lọ ṣe ọdẹ ni gbogbo igba pẹlu rẹ. Ati nihin lai pẹ, ni bi ọdun kan sẹyin, dokita ṣe iṣẹ abẹ fun un (o ni arun jẹjẹrẹ) dokita naa si sọ wipe, “O ti ku.”

Mo wa ro o wipe, “Ọrẹ mi atijọ ọwọn.” Ogun-na-gbongbo jagunjagun ti Ogun Agbaye Kinni, ọkunrin takuntakun ninu ẹbi rẹ. Mo ṣe iribọmi fun un ni orukọ Jesu Kristi ni ọpọlọpọ ọdun ṣeyin fun imukuro awọn ẹṣẹ

rẹ, ni mimọ nigba naa pe a ti bi i si inu ara Kristi ati wipe o ti ṣetan lati pade Ọlọrun. Mo ro o wipe, “Arakunrin mi iyebiye ti n tẹsiwaju bayi.” O jẹ lẹyin iran naa gan an.... tabi, ki iran naa to tọ mi wa nipa ọrun. Mo si lọ lati ri i ati ninu iyara naa ni oṣumare ti fi ara han. Ọlọrun ma a n yi ohun gbogbo pada. Eyi jẹ bi ọdun kan, o le oṣu kan sẹyin, o si wa nihin sibẹ loni o n bu ata.

13 O jẹ ohun kan bi i.... O jẹ ohun kan bi i oogun Koro o Sufuru, eyi ni o jo o n ọna ọfun nihin. Mo ro wipe yoo to fun adura ni owurọ yii. Ma a bọ loke, mo mọ wipe emi yoo kede iyẹn lẹyin ti Billy ti pin tan.... tabi emi yoo, ti mo mọ pe wọn yoo pin kaadi adura. Mo sọ fun ọkọ ọmọbinrin rẹ, ọrẹ mi ọwọn Arakunrin Creech, pe ki o mu un wa si òkè. Mo si ro wipe, bi mo ba kuna lati rii nigba naa, emi yoo mu un wa emi yoo si fi si inu ọkan ninu awọn iyara adura nihin. Ṣugbọn o ti ri kaadi adura gba, mo si wipe, “Busty, mo fẹ ki o jade lọ si ibẹ yẹn.” Everett ni orukọ rẹ, awa sa a ma a n pe e ni akekuru ni Busty. Mo sọ fun un pe, “Jade lọ ki o si to sinu un ila adura, yoo tẹ mi lọrun bi mo ba gba adura fun ọ nigba ti ami-ororo ba sọkalẹ fun adura. Nitori naa, emi yoo fẹ ẹ bẹẹ. Mo mọ wipe bi mo ba fẹ ki ẹnikan gbadura fun mi, emi yoo fẹ ẹ nigba ti itami-ororo ba sọkalẹ si ori ẹni na a.

14 Wayi, ẹ jẹ ki a ṣi Bibeli wa ni owurọ yii, ki a ṣi i si Iwe Rutu. Emi yoo si ka awọn Iwe Mimọ kan lati inu rẹ, lati inu Iwe Rutu. Wayi, ki a to lọ ninu ẹkọ pataki yii, bi emi yoo ba si ṣe bẹẹ, emi yoo kede akori iwaasu mi fun owurọ yii. Ohun ni a n pe ni, “Ibatan Olurapada Naa.” Emi yoo si fẹ lọ ninu rẹ ni ọna mẹrin ọtọọtọ lori I ọrọ irapada.

Mo ro wipe ni alẹ Ọjọ Aiku ti o kọja mo n waasu lori bi Kristi ṣe wa lati ra wa pada. Ati loni, mo fẹ sọrọ lori “Tani Olurapada kan jẹ? Ati bawo ni O ṣe jẹ Olurapada? Si ranti, Olurapada yoo ra ọ pada patapata nigba ti O ba ra ọ pada kuro ninu awọn ẹṣẹ rẹ, kuro ninu aisan rẹ, kuro ninu ohun gbogbo ti o ba kuna. Olurapda ni O jẹ.

Wayi, ki a to lọ ninu ẹkọ yii, ẹ jẹ ki a tẹriba ki a si sọrọ si I nipa adura. Wayi, pẹlu ori wa ni titẹba, mo n roo wo pe awọn melo ni owurọ yii ni iwaju Ọlọrun ni wọn yoo fẹ ki a ranti awọn ninu adura nipa gbigbe ọwọ wọn soke ti wọn yoo si sọ wipe, “Ọlọrun Iwọ mọ ẹbẹ adura mi? Ki Ọlọrun ki O bukun ikọọkan yin.

15 Baba wa ọrun, inu mi dun pupọ loni pe Agbara nla kan ti o ga wa, ni mimọ pe Ọlọrun ni O jẹ, pe a lee tọ Ọ wa nipasẹ Ọmọ Rẹ Kristi Jesu, ki a si ri idahun gba si ohun ti a ba beere. Gẹgẹ bi o ti ri ninu awọn ipade ti wọn ti rekọja lọ, awa n sọrọ nipa bi eniyan ti n rin kiri ni awọ agutan, ati awọ ewurẹ ti o si jẹ alaini, ti o n wa ilu kan ti olukọ ati ẹlẹda rẹ jẹ Ọlọrun. Ni mimọ wipe bi awọn ba le e de ọdọ Rẹ lẹẹkanṣoṣo, bi wọn ba lee mọ ibi ti O wa.... Gẹgẹ bii Joobu ti atijọ, ti o wipe, “Bi emi ba lee kan ilẹkun Rẹ.” Ni ọrọ miran, “Bi emi ba lee mọ ibugbe Rẹ, emi yoo lọ si ile pẹlu Rẹ, emi yoo si ba A fi ikun-lu-ikun ni oju-koju.” Ṣugbọn ko si ọna fun eniyan lati ṣe bẹẹ nitori pe o ti ṣẹ, o si ti ya ara rẹ sọtọ, o si ti di alejo si Ọlọrun.

Ṣugbọn nipasẹ Ẹni iyebiye yii, Ẹni ti O wa ti O si la ọna na a, ti o si dari awọn ẹṣẹ wa ji wa.... ti O si mu wa wa si iwaju Ọlọrun, ki i ṣe bi alejo mọ, ṣugbọn bi i ọmọkunrin ati ọmọbinrin ti wọn n wa si ọdọ Baba wọn, ni mimọ wipe Oun yoo fi fun wa gbogbo ẹbẹ kọọkan bi awa beere. Ofin kan pere ni a fi lelẹ, eyi ni pe, “Bi iwọ ba lee gbagbọ.” Eyi si ni adehun naa. Satani fi ọwọ sọya wipe awa ko ni Gbagbo, Ọlọrun si sọ wipe awa yoo gbagbọ! Bayi ogun naa n lọ lọwọ, ipinnu naa si jẹ ti awa lati ṣe, bi yoo ṣe ri niyi. A si kọ ọ ni ni ọna ti o ya ni lẹnu pupọ pe, “Ohun gbogbo ni o ṣeeṣe fun awọn ti wọn gbagbọ.”

16 Loni awa n gbagbọ

Ni wiwa, awa n tọ Ọ wa fun ojurere ti ọrun, a si n beere pe ki Iwọ ki o gba awọn ẹbẹ wa. Ati pe ni abẹ gbogbo ọwọ ti o lọ si oke ati ni abẹ ọkan naa Iwọ mọ ohun ti a ni lọkan. Nitori a ti kọ ọ pe Iwọ mọ gbogbo ète ati ero ti inu, Iwọ si le e mọ ọkan ero yatọ. A si gbadura, Ọlọrun, pe ki Iwọ fi idahun, ni ibamu pẹlu ọrọ ati oore-ọfẹ Rẹ, fun gbogbo ẹbẹ wa kọọkan ti a ti sọ.

Awa yoo si tun beere loni, Oluwa, pe ki O ran mi lọwọ, emi ti, boya mo jẹ alaini julọ, ninu agbo yii; ni mimọ wipe a gbe ohun naa ti a fi ẹjẹ Jesu Oluwa ra si iwaju mi. Boya a ni awọn ẹlẹṣẹ ti wọn joko nihin awọn ti a ti fi ẹṣẹ de to bẹẹ gẹ ti o fi jẹ wipe yoo nira fun wọn tabi boya ko tilẹ le ṣeeṣe fun wọn lati na ọwọ jade de ibi ti wọn yoo ti lee tẹwọ gba Kristi, niwọn igba ti satani ti fi agbara rẹ de wọn. Ṣugbọn ni mimọ wipe a ti kọ ọ pe, “Ni orukọ Mi wọn yoo le ẹmi eṣu jade.”

17 Iwọ fun wa ni agbara loni, Oluwa, nipa iwaasu Ọrọ Ọlọrun naa lati le gbogbo ẹmi eṣu ti iyemeji, igbagbọ asan ati ẹru kuro ni inu ati ọkan awọn eniyan, ti o fi jẹ wipe a o lee mu, awọn ti a ti fi iporuru-ọkan ati iyemeji de, wa si abẹ apa Kristi. A si tun ti kọ ọ wipe, “Wọn yoo gbe ọwọ le awọn alaisan, ara wọn yoo si da.” Awọn kan wa nihin ti wọn jẹ Kristẹni ti a si ti fi ẹmi-eṣu ti aisan de.

Oluwa, fun mi ni agbara Ẹmi Mimọ loni lati da ni ide gbogbo awọn ti wọn n ṣe aisan ati awọn ti a n pọnloju ti wọn wa ninu gbọngan yii loni, ki Ẹmi Mimọ nla naa le e ni ipo-ti-o-ga-julọ ni ọkan kọọkan ati ninu ara

kọọkan ti o wa ni iwaju Ọlọrun. Bawa sọrọ nipa Ọrọ Rẹ. Otitọ ni Ọrọ Rẹ. emi ti n ko mọ ohun ti mo lee sọ, ṣugbọn ti mo n duro de idari Ẹmi Mimọ, ki O lee dari ki O si ṣe amọna wa si inu gbogbo otitọ. Gba bẹẹ fun wa, Oluwa. Gba gbogbo ogo fun Ara Rẹ. Si ta ami-ororo le iranṣẹ Rẹ. A ti ta ami-ororo le Ọrọ Rẹ. Awa yoo fi iyin fun Ọ, bi O ti ṣe n fi Ọrọ naa fun gbogbo ọkan kọọkan bi a ṣe nilo rẹ. Ni orukọ Jesu Kristi, Ọmọ Ọlọrun ni a beere rẹ. Amin.

18 Ki a to bẹrẹ kika Iwe Mimọ, mo lee sọ ọrọ kekere ti o wọpọ fun mi lati sọ yii, eyi ti mo nifẹ pupọ;

Bi o ba ni awọn odo ti iwọ ko lee re kọja,

Ti o si ni awọn oke nla ti iwọ ko le e gun,

Saa ranti pe, ohun ti o rọrun julọ fun Ọlọrun ọrun lati ṣe ni awọn ohun ti awọn eniyan miran ko lee ṣe.

Emi yoo ka lati inu Iwe Rutu ori kinni;

*O si ṣe ni ọjọ wọn ni ti awọn onidajọ n ṣe olori,.... iyan kan si mu ni ilẹ na a. Ọkunrin kan lati Betilẹhẹmu-Juda si lọ ṣe atipo ni ilẹ Moabu, oun ati obinrin rẹ ati awọn ọmọ rẹ ọkunrin meji*

*Ọrukọ ọkunrin naa a si ma a jẹ Ẹlimẹlẹki, ati.... orukọ obinrin rẹ a si ma jẹ Naomi,.... orukọ awọn ọmọ rẹ.... a si ma jẹ Maloni ati Kiloni, awọn ara Ẹfrata ti Bẹtilẹhẹmu-Juda. Wọn si wa si ilẹ Moabu, wọn si n gbe ibẹ.*

*Ẹlimẹlẹki ọkọ Naomi si ku.... o si ku oun, ati awọn ọmọ rẹ ọkunrin mejeji.*

*Wọn si fẹ aya ninu awọn obinrin Moabu; orukọ ọkan.... a ma jẹ Ọrpa,.... orukọ ekeji a si ma jẹ Rutu: wọn si wa nibẹ niwọn ọdun mẹwa.*

*… Awọn mejeji, Maloni ati Kiloni, si ku pẹlu, obinrin naa ni o si ku ninu awọn ọmọ rẹ ọkunrin mejeji ati ọkọ rẹ.*

*Nigba naa ni o si dide pẹlu awọn aya-ọmọ rẹ, ki o le pada lati ilẹ Moabu wa: nitori pe o.... ti gbọ bi.... Oluwa ti bẹ awọn eniyan Rẹ wo ni fifi ounjẹ fun wọn.*

*O si jade kuro ni ibi ti o gbe ti wa, ati awọn aya-ọmọ rẹ mejeji pẹlu rẹ, wọn si mu ọna pọn lati pada wa si ilẹ Juda.*

*Naomi si wi fun awọn aya-ọmọ rẹ mejeji pe, Ẹ lọ ki olukuluku pada lọ si ile iya rẹ, ki Oluwa ki o ṣe rere fun un yin gẹgẹ bi ẹyin ti ṣe fun awọn oku, ati fun mi.*

*Ki Oluwa ki o fi fun yin ki ẹyin le ri isimi, olukuluku yin ni ile ọkọ rẹ. Nigba naa ni o fi ẹnu ko wọn lẹnu; wọn si gbe ohun wọn soke wọn si sọkun.*

*Wọn si wi fun pe, ni tootọ awa yoo ba ọ pada lọ sọdọ awọn eniyan rẹ*

*Naomi si wipe, ẹyin ọmọbinrin mi ẹ pada: eeṣe tị eyin o fi ba mi lọ? Mo ha tun ni ọmọkunrin ni inu mi, ti wọn iba fi ṣe ọkọ yin?*

*Ẹ pada, ẹyin ọmọbinrin mi, ẹ ma lọ, nitori emi di arugbo ju ati ni ọkọ. Bi emi wipe, emi ni ireti, bi emi tilẹ ni ọkọ ni alẹ yii ti emi si bi ọmọkunrin;*

*Ẹyin ha le duro de wọn titi wọn yoo fi dagba? Ẹyin o le duro de wọn ni aini ọkọ? Rara o, ẹyin ọmọbinrin mi; nitori inu mi bajẹ gidigidi nitori yin, ti ọwọ Oluwa fi jade si mi*

*Wọn si gbe ohun wọn soke, wọn si tun sọkun: Orpa si fi ẹnu ko iya-ọkọ rẹ lẹnu; ṣugbọn Rutu famọ ọn.*

*Oun si wipe, kiyesi i orogun rẹ pada sọdọ awọn enyan rẹ ati sọdọ oriṣa rẹ; iwọ pada tẹle orogun rẹ.*

*Rutu si wipe, maṣe rọ mi lati fi ọ silẹ, tabi pada kuro lẹyin rẹ; nitori ibi ti iwọ ba lọ, ni emi o lọ, ibi ti iwọ ba si wọ, ni emi o wọ: awọn eniyan rẹ ni yoo ma ṣe eniyan mi, Ọlọrun rẹ ni yoo si maa ṣe Ọlọrun mi:*

*Ibi ti iwọ ba ku ni emi o ku si, nibẹ ni a o si sin mi; ki Oluwa ki o ṣe bẹẹ si mi, ati ju bẹẹ lọ pẹlu, bi ohun kan bikoṣe iku ba ya iwọ ati emi.*

19 Mo fẹ fun iwaasu kekere ti a o wa ni owurọ yii ni akọle kan bi mo ṣe nkọ ọ, ti mo si n gbiyanju lati mu

igbagbọ nipa irapada kan wa fun un yin, niti ohun ti o jẹ ati bi a ti n gba a, mo fẹ mu akori yi wa fun un yin ti i ṣe; Ibatan Olurapada Naa.“

Bayi, lati ra ohun kan pada ni lati mu un pada. Ohun kan ti o ti sọnu bii ki a fi nnkan sinu ile itaja ipasipaarọ kan. Iwọ si lọ lati ra a pada. O ra a pada pẹlu owo. O jẹ ohun ini rẹ, lẹhin ti o ti ra a pada. Ṣugbọn ofin ti Israeli ni pe o ni lati jẹ ibatan lati gba ohun ini kan ti o ti sọnu pada.

20 Itan wa bẹrẹ ni igba awọn alakoso Israẹli ti wọn jẹ adájọ́, lẹhin iku Joṣua. Lati le ri aworan ti o dara yi, iwọ ka ori marun tabi mẹfa akọkọ ti Iwe Samuẹli kinni; iwọ yoo si ri okodoro itan naa.

Ṣugbọn a o fo awọn nnkan kan bayi lati le e de ibi pataki iwaasu na a gan an, ti o sii jẹ wipe nigba kan, mo bẹrẹ pẹlu Iwe Rutu yii, mo si wa ni ori rẹ fun bii ọsẹ mẹta tabi mẹrin ki n to pari rẹ. Nigba kan mo bẹrẹ pẹlu Iwe Ifihan, mo si lo bi i odidi ọdun kan lati pari ẹkọ lori rẹ. A si n so Iwe Mimọ kekere kọọkan mọ Iwe mimọ miran titi ti a fi lọ ninu gbogbo Bibeli. Eyi si rẹwa pupọ. Nitori naa awa mọ wipe a mi si Bibeli. Nitori pe nipa ẹkọ iṣiro ati ni gbogbo ọna gbogbo.... Ko si iwe àròkọ kan ti a kọ ti ko ni tako ara rẹ ni ibi kan.

A kọ iwe yii fun bi ẹgbẹrun ọdun mẹrin si ara wọn, iyẹn awọn iwe inu Bibeli. A si kọ awọn iwe yii lati ọwọ.... Mo ti gbagbe iye awọn ọkunrin ti wọn kọ Bibeli. Mo si ranti nigba kan ṣugbọn, mo tọrọ aforiji. Mo fẹ sọ wipe ọkunrin ọgọta tabi ju bẹẹ lọ. Ṣugbọn mo lee kuna lori eleyi [Ẹni kan sọrọ lati inu ijọ] Ogoji. Awọn ogoji ọkunrin ni wọn kọ Bibeli, laarin ọpọlọpọ ẹgbẹrun ọdun si ara wọn, ti awọn ọkunrin wọnyii ko mọ ara wọn, ti wọn ko si ri awa wọn ri, tabi ki ẹnikan ka ohun ti ẹnikeji ti kọ ki oun to kọ tirẹ ni ọpọlọpọ igba, ko si wa si ẹyọ ọrọ kan ti o tako ekeji. A mi si Ọrọ Ọlọrun naa.

21 Wayi ọpọlọpọ awọn eniyan n wo Iwe Rutu yii, gẹgẹ bi wọn ṣe n sọ, wọn ni, “Itan Ifẹ Bibeli ni.” Bibeli jẹ itan ifẹ. Gbogbo Bibeli jẹ itan Ifẹ.

Ki i ṣe wipe o jẹ itan ifẹ nikan, o jẹ woliii. Ki i ṣe wipe Bibeli jẹ woliii nikan, o tun jẹ itan. Kii ṣe wipe o jẹ itan ifẹ, itan kan, woliii kan, ṣugbọn Ọlọrun funra Ara Rẹ ni o jẹ. Nitori pe, “Ni atetekọṣe ni Ọrọ wa, Ọrọ yii wa pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si ni Ọrọ naa.” Nitori naa Ọrọ yii jẹ Ọlọrun ti a tẹ sinu iwe. Ẹyin ara, eyi yẹ ki o yanju ọrọ naa. Ọlọrun ti a tẹ sinu iwe. Jeofa ti a tẹ sinu iwe kan. Ko si si ikan kan ninu rẹ ti o jẹ itan arosọ, ṣugbọn o jẹ otitọ pọnbele, so ọkan rẹ rọ lori gbogbo àpólà gbolohun kọọkan rẹ. O wa nibẹ, otitọ si ni. Ọlọrun yoo si ti Ọrọ Rẹ lẹyin.

22 A si kọ itan yii.... Ani gbogbo awọn iwe mimọ ti atijọ (awọn ọkunrin mimọ), nigba ti wọn n gbiyanju lati ko awọn Iwe Mimọ ti Majẹmu Laelae jọ, Iwe Rutu yii jẹ ọkan pataki ninu awọn Iwe naa ti o jẹ itẹwọgba. Eeṣe? O jẹ itan ifẹ, eeṣe ti awọn onkọwe naa ati awọn eniyan mimọ ti Majẹmu Laelae fi gba iwe yii gẹgẹ bi eyi ti a mi si? Idi ni pe iṣipaya ti o farasin kan wa ninu rẹ. Ati bi o ba si loye iṣipaya ti o fi-ara-sin yii, eyi yoo mu ki o sunmọ Ọlọrun pupọ gidigidi.

Mo si gbadura pẹlu gbogbo ọkan mi ni owurọ yii pe ki Ọlọrun de gbogbo ọkan kọọkan mọlẹ, titi ti Oun yoo fi fi Ara Rẹ han gẹgẹ bi Oun ṣe ri, ninu itan yii - Ohun ti Oun jẹ si ọ, ati bi iwọ yoo ṣe tẹwọgba A. Nigba ti o ba si ri eyi lẹẹkanṣoṣo pere, yoo rọrun to bẹẹ gẹ ti yoo fi ṣe ọ ni kayeefi idi ti iwọ ko fi ri i bẹẹ tẹlẹ. Ṣugbọn awa le e ni iṣipaya eleyi nipa Ẹmi Mimọ Rẹ naa.

23 Bayi, ọpọ, ọpọ ninu awọn ti n ka Bibeli, n kaa a.... wọn yoo sa dide wọn yoo si ka oju ewe kan, wọn yoo tun ka oju ewe kan. Ni ṣiṣe bayi, iwe yi ko le ye ọ nitori ni ọna aditu ni a gba kọ ọ. Jesu dupẹ lọwọ Ọlọrun ti o jẹ ko ri bẹ. O wipe 'Ẹ fi Ọrọ yi pamọ fun awọn ọlọgbọn ati awọn amoye, E si fihan fun awọn ọmọ ọwọ awọn ti yoo kọ ẹkọ.'

Bi mo ṣe maa n sọ, iyaafin Branham ni o joko lẹhin mi ni owurọ yii, ṣugbọn nigbati mo ba wa ni oke okun, oun yoo kọ iwe si mi, yoo sọ pe, “Olufẹ mi Bill, mo joko ni ibi yi ni alẹ yii pẹlu awọn ọmọ; mo ronu nipa rẹ.” Yoo si tẹsiwaju lati sọ kọ ohun gbogbo ti o ba fẹ kọ. Ṣugbọn mo ni ifẹ rẹ, mo si mọ ọn dara dara, mo le sọ oun ti o ni lọkan, mo mọ ohun ti o fẹ sọ gẹlẹ, ẹ rii, boya o kọ sinu iwe tabi ko kọ ọ. Ẹ rii? Nitori mo mọ oun ti o n sọ. Bawo ni o ṣe ri bẹ? Ẹni ti o sunmọ mi ni. Ọkan ni wa, ẹ rii. O si mọ iṣe mi. Emi naa si mọ iṣe rẹ.

Ko ni ṣe.... O le joko ki o si wo mi, mo lee sọọ fun ọ ohun ti yoo sọ, ẹ rii. Nitori mo mọ gidigidi. Oun naa le ṣe bẹ si emi naa. Bayi kinni o jẹ ki eyi ri bẹẹ, igbekẹle ninu ara wa ni. Ifẹ ni.

24 Laarọ ana a pẹ ni ori ibusun, awọn ọmọ ko lọ si ile-iwe, a sii n sọrọ lori oriṣiriṣi awọn nnkan, ati bi o ti jẹ wipe.... “Kinni ikorira?”

Mo wipe, “Ikorira ni ìbẹ̀rẹ̀ yoo si ni òpin. Ifẹ ko ni ibẹẹrẹ, nitori naa ko ni ni opin.” Ikorira wa titi lae. Ifẹ yoo wa titi ainipẹkun. Ikorira ni ibẹrẹ, ikorira si ni opin. Ifẹ ko ni ibẹrẹ ko si ni ni opin. Ẹ rii, ainipẹkun ni.

Nigba ti ọkunrin kan ba ri obinrin kan ti o fẹran ti o ṣe igbeyawo pẹlu rẹ nitori wipe, o ni ẹwa, opin yoo de

ba iyẹn. Ṣugbọn nigbati ọkunrin kan ba ri obinrin ti o ni ifẹ si - ti oun ko si mọ idi rẹ, ṣugbọn ti o saa ni ifẹ rẹ - ti obinrin ba ri ọkunrin kan ti o ni ifẹ lai fẹ mọ bi o ṣe ri ni oju, o saa nifẹ rẹ, obinrin naa si ni ifẹ ọkunrin naa ni - awọn jẹ awọn meji ti wọn yoo wa papọ ninu ọjọ ainipẹkun ni wọn. Iku tabi ohunkohun ko le ya wọn. Nitori wọn wa lati ainipẹkun, wọn sọkalẹ si inu saa akoko, wọn yoo si tun pada si inu ainipẹkun. Ainipẹkun ti sọkalẹ si ara ti a n pe ni akoko, yoo si tun pada lọ si ainpẹkun. Ko le ṣegbe.

25 Obinrin ti o ni ẹwa, ẹwa yi yoo sá, iyẹn daju.... Ẹ fun ni ọdun melo kan si. Boya loni o n lọ ni oju pópó, obinrin kekere ti ko wọ aṣọ daradara - ẹni ti n rán awọn ọkan kan lọ si ọrun apadi ju awọn ile oti ti o wa ni orilẹ ede lo. Ṣugbọn yoo maa lọ ara rẹ ni oju pópó, pẹlu ero wipe oun jẹ nkan. Bi Bibeli ṣe sọ, wọn yoo ni ọrùn nina, wọn n rin, wọn n yi [iyẹn jẹ wọn nlọ] bi wọn ṣe ńlọ, ni awọn opin ọjọ. Wọn mu Iwe Mimọ sẹ, wọn ko si mọ ọ. Wọn yoo duro ni iwaju ile pelu awọn aṣọ ibajẹ lọrun awọn ọkunrin yoo maa wo wọn, wọn ko si ni mọ (o le jẹ oniwa rere si ọkọ rẹ tabi ọrẹkunrin rẹ bi o ti le jẹ to), Ṣugbọn ni ọjọ idajọ yoo dahun fun siṣe Agbere pẹlu awọn ọgọrun ọkunrin. Ẹmi kan wa lori wọn, wọn ko si mọ. Bibeli wipe, “o wa ni ihoho, o fọju ko si mọ bẹẹ.” Ohun irira ni wipe ko mọ ọn!

Njẹ o mọ wipe ara kekere ti o duro daradara ti Ọlọrun fun ọmọdebinrin naa le jẹẹra ni iwoyi ọjọ aiku ti o n bọ? Ọkunrin ti o ga, ti o dudu ti o lẹewa naa le di okiti ẹgbin lasan ni iwoyi ọjọ aiku ti n bọ. Gbogbo ara wa yii n ṣegbe. Ṣugbọn ẹni ti o wa ni inu lọhun - Ọlọrun, ti ṣe ifẹ - n gbe titi ainipẹkun. Nitori naa kiyesi, ti inu naa. Fi oju rẹ si ibi ilepa naa.

26 Bayi itan yii beere ni ọna yii; bi obinrin ti o ṣee fẹran, ti o si dụn, ọrukọ rẹ ni Naomi. Itumọ Naomi ni “adun” Ẹlimẹlẹki jẹ ọkọ rẹ, oun tumọ si isin'. Isin aladun ni ẹbi wọn. Wọn ni ọmọkunrin kan, Mahlon, orukọ rẹ eyi tumọ si “Aisan,” ati Kiloni eyi ọmọkeji tumọ si “aarẹ, irẹwẹsi, ibanujẹ.” Eyi ni ẹbi naa.

O sị ṣe.... Iyàn kan bẹ silẹ̀ Israẹli. Asiṣe akọkọ ti ọmọ Juu kan lee ṣe ni ki o fi ilẹ naa silẹ. Ọlọrun ni o fun wọn ni ilẹ naa. Nigbati a fun Abrahamu ni ilẹ naa, Ọlọrun sọ fun wipe ki o ma ṣe fi ilẹ naa silẹ. O sị ṣe asiṣe nigbati o lọ si Gẹra, o wọ inu iṣoro. Ko yẹ ki Juu kan fi Palẹstini silẹ. Ati mu wọn jade lati inu ibi gbogbo aye, ati bayi wọn n pada bọ ọ.

27 Oo, o jẹ itan ti o rẹwa pupọ, ti a ni nihin ni owurọ yi! Wọn n pada a bọ.

Ìyàn ni o le Naomi kuro ni ilẹ naa, oun ati ọkọ rẹ si lọ si ilẹ Moabu.

Bayi, lati loye ibẹrẹ itan yii, ki o lee ye yin bi ẹ ti n fi eti silẹ. Wayi, awọn ara Moabu, awọn ara Moabu naa, dide wa lati ọdọ ọmọ ti ibi rẹ ko ba ofin mu. Eyi ti i ṣe ọmọbinrin Lọọti. Lẹyin ti wọn ti ja ajabọ kuro ninu ina Sodomu, nipa oore-ọfẹ Ọlọrun, lẹyin naa ni awọn ọmọbinrin naa mu baba wọn mu ọti amupara, ti wọn si ni ibalopọ pẹlu Baba wọn gẹgẹ bi i iyawo. Ọkan ninu wọn bi ọmọ kan, ati ọkan ninu wọn wa.... o dide, o si gbe orilẹ-ede Moabu dide. O yẹ ki wọn jẹ Kristẹni, ṣugbọn wọn darapọ pẹlu iboriṣa. Ẹ si rii, fifi ilẹ-ileri silẹ, laifẹ mọ bi o ṣe buru to, lati lọ ṣe atipo ni ilẹ miran, fa iyọnu.

28 Igba-ku-gba ti onigbagbọ kan ba ti ṣako lọ kuro ninu ilẹ ti Ọlọrun ti fun un;.... Ni ọpọ igba sinu oṣelu (idibo kan ni o n bọ ni ọna yii, ati bẹẹbẹẹ lọ) ọkunrin rere kan lee jẹ ẹni rere, yoo si ṣako lọ kuro ninu awọn ilẹ rẹ, gẹgẹ bi oniwasu kan ti mo mọ, ti o lọ lati gbe apoti gẹgẹ bi i alakoso ilu. Nigba ti o si ṣe bẹẹ, o kuro ninu ipo oniwaasu rẹ, Satani si le e ba.

Bi Kristẹni kan ba fi awọn ilẹ wọnni silẹ: “O dara, emi yoo lọ ni aṣalẹ yii, emi yoo joko pẹlu awọn ọmọkunrin ninu ile tẹtẹ fun igba diẹ, eyi ko ni pa mi lara. Emi yoo sa gba igo kan ni.” O ti kuro lori awọn ilẹ rẹ, pada wa! Iwọ n lọ tan ina wa wahala ni.

Oo, gbogbo awọn iyoku ọmọbinrin n mu siga, emi naa yoo naa yoo gbiyanju lati mu siga kan.“ Iwọ ti kuro lori awọn ilẹ rẹ. Maṣe ṣe bẹẹ. Duro si ori ilẹ-ini rẹ.

“O ti daa, gbogbo awọn eniyan ti wọn wa nihin, n pe mi ni ara-oko, wọn ni ẹni atijọ ni mo jẹ.” Duro ni bẹ lọnakọna! Ipo rẹ niyẹn. Duro ninu Kristi.

29 Nitori iyan naa, Naomi, ṣako kuro ni ilẹ naa o si lọ si ilẹ Moabu, lati ri ounjẹ. Ko yẹ ki o ṣe bẹẹ, nitori awọn iyooku ko fi Juda silẹ, ni Bẹtilẹhẹmu. Bẹtilẹhẹmu tumọ si Bẹtẹli, “Ile Ọlọrun, ile iyin.” Wọn si joko nibẹ.

Oun si ṣako lọ pẹlu ọkọ rẹ. Awọn ọmọ rẹ ọkunrin mejeeji si fẹ awọn ọmọbinrin Moabu. Ṣugbọn bi Ọlọrun ba ti yan pe nnkan kan yoo ṣẹlẹ, ohun naa yoo ṣẹlẹ dandan. Idi niyi ti mo fi gbagbọ dajudaju ninu iyantẹlẹ Ọlọrun - Imọ-saaju-ohun gbogbo lati ọdọ Ọlọrun wa.

A wa rii wipe ni ọ̀hún iku kọlu ẹbi naa, wọn si bẹrẹ sii pada sile. Iku pa ọmọkunrin naa - o ku, awọn ọmọkunrin mejeeji ati baba wọn ku. Rutu, Ọrpa ati Naomi wa gbera lati pada.

30 Wayi, mo fẹ ṣe afiwe, ni owurọ yii, Naomi alagba obinrin, gẹgẹ bii ijọ ti ilu gba wọ ile, eyi i ni ni ijọ Juu ti

ilu gba. Rutu ara Moabu, jẹ ijọ awọn ẹya Alaikọla, eyi ti o jẹ ijọ Kristẹni, ijọ tuntun naa.

Mo si fẹ lọ ninu eyi ni abala mẹrin ọtọọtọ: Rutu (mo ti kọ ọ silẹ nihin), Rutu ti o n pinnu, o n ṣe ipinnu rẹ; Rutu ti o n sin; Rutu ti o n simi; Rutu ti o gba ere ipinnu rẹ. Bi a ṣe n pada bayi, Rutu ti o n ṣe ipinnu naa; Rutu, lẹyin ti o ṣe ipinnu rẹ, lẹyin naa Rutu n sin; lẹyin naa Rutu simi; lẹyin naa Rutu gba èrè.

31 Wayi, ni oju ọna pada si ile, àkókò kan de.... Rutu ti o jẹ afiwe ijọ naa, tabi ti Kristẹni naa; gẹgẹ bi aladori ẹni-kọọkan ti jẹ aṣoju gbogbo orilẹ-ede Kristẹni lapapọ. Njẹ iwọ mọ iyẹn? Iwọ, ni iṣe-wu-iwa-rẹ, ni ọna ti o n gba hu iwa ati ohun ti iwọ n ṣe, iwọ jẹ aṣoju fun gbogbo ara Kristi ni apapọ. Iwọ wipe, "Ṣebi ọmọ-ijọ lasan ni mo jẹ." Eyi ko jẹ nnkan kan. Nigba ti o ba bẹrẹ sii jẹ orukọ "Kristẹni" naa, iwọ n ṣe oju Kristi ati ijọ Rẹ. O si n lati gbe igbesi-aye rẹ ni ọna yii. o ni lati gbe bi i ọkunrin ọmọluabi, bi ọmọbinrin ọmọluabi. Maṣe daba laelae lati ṣe awọn ohun kan ti aye, nitori pe oju gbogbo ọrun ati aye n wo ọ, pe ki o jẹ aṣoju ohun kan naa. Ko si bi o ṣe lee jẹ alailera to, ko si bi o ṣe lee kere to, gbe ori rẹ soke taara, nitori pe Kristẹni kan ni o jẹ.

32 Wayi, alaigbagbọ ni Rutu, (o n sin oriṣa), iru ẹnikan naa si ni Ọrpa jẹ. Wọn si wa wa ni oju ọna wọn, ti wọn n pada pẹlu iya-ọkọ wọn, nitori wipe o ti gbọ wipe ni Bẹtilẹhẹmu lọhun, ni Juda, pe Ọlọrun ti mu ajakalẹ-arun naa kuro, ati pe awọn eniyan naa ti bẹrẹ sii ri ounjẹ. O ti wa ni ilẹ Moabu fun bii odidi ọdun mẹwa. Bẹẹ ni Edershem sọ, o nibii ọdun mẹwa (Onpitan ni Edershem.)

Bi Naomi ṣe n pada a bọ, inu rẹ bajẹ (ọkọ ati awọn ọmọ rẹ ti ku), oun pẹlu awọn aya-ọmọ rẹ mejeeji, nigba naa ni o yiju pada si wọn, o di dandan, o si wo wọn, o wipe, "Eeṣe ti ẹ fi ni lati tẹle mi? Wayi, o ni ko si ohun kan ti o le e ṣẹlẹ ju ki ẹ ni wahala lọ. O wipe, "O dun un mi pe ọwọ Ọlọrun ti ba mi lati si i yin."

33 Oye igba melo ni Israẹli ti ronu ni ọna yii? Ti wọn ko mọ wipe gbogbo rẹ jẹ eto Ọlọrun. Bi ogiri ile-ẹkun ti wa ni ode Jerusalẹmu, o si wa nibẹ sibẹ. Awọn okuta atijọ ọ ti tẹmpili, ni wọn sa jọ lati kọ okiri naa. A ti pa a dan pẹlu ẹkun ati igbe ati ọwọ awọn ọmọ Juu, ti wọn n sun ẹkun ti wọn si n bẹ Jeofa wipe, "Jehofaa!" Oye ko ye wọn wipe wakati wọn ti fẹrẹ sunmọ etile. Ogiri ẹkun. "Awọn okuta wọnyi nigba kan jẹ ile fun apoti-ẹri majẹmu Oluwa. Ọba Dafidi wo awọn okuta wọnyi. Oo Jeofa, nibo ni Iwọ wa?" Ti wọn ko si mọ wipe laipẹ Ọba wọn yoo pada, iyẹn Olurapada wọn. A ni lati le wọn jade fun sa a diẹ.

34 O ṣe Naomi ni kayeefi pe, "Eeṣe ti ọwọ Oluwa fi koro si mi, ẹyin iyawo ọmọ mi? Ọlọrun ti ti mi jade. Mo ti di ẹni itanu. Emi ko mọ ohun ti mo ṣe gan an, ṣugbọn ẹni itanu ni mọ jẹ."

Ẹ rii, Ọlọrun n ba eto Rẹ bọ. Nitori pe, ohun gbogbo ni o n siṣẹ papọ fun rere fun awọn naa ti wọn fẹran Ọlọrun. Ohun yoowu ti o lee jẹ.

Naomi wipe, "Ẹ pada si ọdọ awọn iya a yin, ki ẹ si ri isimi gba ninu ile wọn. Awọn ọkọ yin ti ku, ẹ si jẹ ọdọ sibẹ, arẹwa obinrin ni yin. Ẹ pada! Ẹ pada si ibi ti ẹ ti wa, nibẹ ni ki ẹ ti ri isimi. Ki Ọlọrun ki o fi aanu han yin nitori pe ẹ ṣe inu rere si awọn oku. Ẹ si ti gbe igbesi-aye iwa rere lati igba ti awọn ọkọ yin, ti ku. Ẹ si ti fi inu rere han si mi pẹlu, emi opo obinrin arugbo, ti ko ni ọkọ, ẹ ko si fi mi silẹ. Ẹ pada, ki Ọlọrun ki O si fun yin ni isimi ni ile yin. Wọn si sun ẹkun.

35 Naomi wipe, "Mo ti di arugbo, emi ko si lee bi ọmọ mọ. Bi mo ba tilẹ ni ọkọ ti mo si bi ọmọ, anfani wo ni iyẹn yoo ṣe? Ẹyin ko ni le duro de ọmọ naa. Ofin gan an ni awọn ọjọ atijọ ni yẹn. Iyẹn nipe bi arakunrin kan ba ku, ati ti oun.... bi arakunrin rẹ kan ko ba ti i ni iyawo, o ni lati fẹ iyawo oloogbe lati pa orukọ arakunrin rẹ mọ ti o ti di oloogbe. "Ṣugbọn", Naomi wipe, "Ẹyin ko ni lee duro de e, iyẹn awọn ọmọ ti mo ba bi. Nitori naa, ẹ pada, ki ẹ si ri isimi gba ninu ile awọn ọkọ yin. Ẹ pada si ọdọ awọn iya yin."

Ati Ọrpa, akawe ijọ ko-gbona-ko-tutu ti o bẹrẹ irin-ajo igbagbọ nigba kan, apẹẹrẹ ijọ ti ko ni ba irin-ajo naa de opin, wipe, "O dabi ẹni pe ọrọ ti o dara ni o sọ yii." Nitori naa, o fi ẹnu ko iya-ọkọ rẹ lẹnu, o si pada. Apẹẹrẹ onigbagbọ ọ ko-gbona-ko-tutu, ti yoo gba Jesu gbọ pe o jẹ Kristi, lẹyin ti yoo gba Jesu gbọ pe o jẹ Kristi, lẹyin naa ti yoo tun wa yi pada sẹyin si inu awọn nnkan ti o ti jade ninu wọn tẹlẹ ri ni. Si ọkunrin naa ti yoo ṣe ipinnu lati lọ pẹlu awọn eniyan Ọlọrun diẹ ti a kẹgan, ati lẹyin naa ti yoo tun wa yi pada ti yoo pada sẹyin, "Gẹgẹ bi aja ti o pada si inu ebibi rẹ, ati ẹlẹdẹ ti o pada sinu wiwẹ ninu ẹrẹ," bi Bibeli ti sọ.

36 Wayi, o pada sọdọ awọn oriṣa rẹ. Ni ọpọ igba awa n pada si ọdọ awọn oriṣa ti ipilẹṣẹ wa. Boya a ni oju ifẹ-ku-fẹ si awọn ohun ti o kuna. Awa yoo pada si sise ifẹkufẹ lẹẹkan sii. Boya a ni oriṣa ti ọti mimu, oriṣa ti siga mimu, oriṣa ti irọ pipa, oriṣa ti ole jija, ati gbogbo oriṣiriṣi oriṣa bẹẹ; ti a si jẹwọ ẹṣẹ wa, ti a si ṣe itẹbọmi fun wa, lẹyin naa ti a wa pada sẹyin. Ohun ibanijẹ ni o jẹ. Iwọ ranti pe a ko da orukọ rẹ mọ titi laelae. A yọ ọ bi ẹni yọ jiga jade nitori ipinnu rẹ.

Ijọ ko-gbona-ko-tutu, onigbagbọ ko-gbona-ko-tutu-ani gẹgẹ bi onigbagbọ kọọkan ṣe jẹ aṣoju fun ijọ. Ọmọ ijọ Amẹrika kọọkan jẹ aṣoju Amẹrika. Ọmọ ijọ Germany kọọkan duro fun orilẹ-ede Germany. Gbogbo kristẹni kọọkan jẹ aṣoju Kristi!

37 Nihin, Ọrpa pẹyinda, lati pada lọ sinu awọn nnkan ti o ti jade kuro ninu wọn, Bi o ṣe jẹ wipe awọn ọkunrin, awọn oniwaasu paapa nigba miran yoo tẹwọgba ọna Oluwa, ati nigba ti o ba ba wọn sọrọ nipa ibaptisimu ti Ẹmi Mimọ, wọn yoo wipe, "Ohun ti ko mu ọgbọn lọwọ ni!" - wọn yoo pẹyinda kuro ninu rẹ. Ọrpa niyẹn.

Sọ fun wọn nipa orukọ Jesu Kristi, pe ko si orukọ miran labẹ ọrun, laarin awọn eniyan nipaṣẹ eyi ti a fi le gba ọ la. Ohunkohun ti o ba sọ ni ọrọ tabi iṣe, ṣe e ni orukọ Jesu Kristi." Bi ko ba si orukọ miran ni abẹ ọrun nipaṣẹ eyi ti a fi lee gba ni la.... Nigba naa Peteru ni ọjọ Pẹntikositi, sọ wipe, "Bi o ba fẹ ni igbala, ronupiwada ẹṣẹ rẹ, ki a si baptisi rẹ ni orukọ Jesu Kristi fun imukuro ẹṣẹ rẹ."" Bi a ṣe pa awọn ẹṣẹ naa rẹ niyẹn. Ati ọkunrin kan, nitori okiki aye - ti ko lee di Bibeli mu lori rẹ - ṣugbọn nitori okiki-aye-ti yoo ṣe odigboṣe fun ijọ, ti yoo ṣe odigboṣe fun Ọrọ Ọlọrun ti oni, ti yoo ki Kristi pe o di-igboṣe, ti yoo si wa pada si inu aye, ni ibi ti a ti hu u jade. Ọrpa ni-ko-gbona-kututu ni, a o ta a danu ni.

38 Ṣugbọn, oo bi mo ti ni ifẹ Rutu naa to! O nilati ṣe ipinnu. Emi pẹlu ni lati ṣe ipinnu. Iwọ pẹlu ni lati ṣe ipinnu. Iwọ ko ni jade kuro ni awọn ẹnu ilẹkun wọnyii ni owurọ yii lai ṣe ipinnu kan tabi ekeji. Iwọ ko ni i fi iyara yi silẹ loni.... Yala ki o jẹ ọkunrin tabi obinrin ti o dara ju bi o ṣe jẹ tẹlẹ lọ tabi ki o jẹ ọkunrin tabi obinrin ti yoo buru ju bi ti ṣe jẹ tẹlẹ lọ; ọkan ni yoo ṣẹlẹ ninu mejeeji. Bi o ba kọ Ọrọ yi i, iwọ yoo buru ju bi o ti jẹ tẹlẹ lọ. Yoo nira ni igba keji ti iwọ yoo gbọ ọ ju ti akọkọ lọ fun ọ lati gba a. Tabi ki igbesi-aye rẹ ki o dara ju ti tẹlẹ lọ.

Akoko gbangba-dẹ-kun, kedere bẹẹ wo kan de ni igbesi aye rẹ. Gbangba dẹkun kan ma a n waye ni igbesi-aye ẹni kọọkan. Rutu si ni lati ṣe ipinnu rẹ. Nitori naa, Bibeli wipe iya-ọkọ rẹ sọ fun un pe, "Pada si ọdọ awọn oriṣa rẹ ti arabinrin rẹ ti ṣe. Pada bi ẹni ko-gbona-ko-tutu ti ṣe. Eeṣe ti iwọ ko fi pada."

Oniwaasu ihinrere naa, "Bi iwọ ba fẹ pada, nigba naa pada!" Oniwaasu otitọ pọnbele naa ti yoo waasu Ọrọ naa ni iwaju awọn ẹgbẹ awọn eniyan naa, ti yoo wipe, "Ẹ ṣe ipinnu yin! Iwọ dide duro ni ori ẹsẹ rẹ!" Ko gbona-ko-tutu naa, onigbagbọ kumọ-kumọ naa, ẹni ti o jẹ ẹsẹ kan ni ile ati ẹsẹ kan ni ode, ko ni sọ bẹẹ. Ṣugbọn iranṣẹ Ọlọrun tootọ yoo gbe e kalẹ ni iwaju rẹ, oun yoo wipe, "Ṣe ipiinu rẹ."

39 Rutu wipe, "Emi yoo ba ọ lọ si ibi ti o ba lọ. Awọn eniyan rẹ yoo jẹ eniyan mi. Ọlọrun rẹ yoo jẹ Ọlọrun mi. Ni ibi ti o ba gbe ni emi yoo gbe. Ni ibi ti o ba ku si ni emi yoo ku si. Ni ibi ti a ba sin ọ si ni a o sin mi si." Ipinnu gidi ni eyi.

"Oluwa, emi yoo gba Ọ gẹgẹ bi i Olugbala mi. Bi Bibeli ba sọ wipe, "Ẹ ronupiwada, ki a si baptisi yin ni orukọ Jesu Kristi," ohun ti emi yoo ṣe niyẹn. Bi Bibeli ba wipe mo ni lati gba Ẹmi Mimọ, iyẹn ni emi yoo ṣe. Bi Bibeli ba sọ fun mi pe, ọkan ni Jesu Kristi ni ana, ati ni oni, ati titi laelae, iyẹn ni emi yoo gbagbọ Emi yoo gba Bibeli ati Ọlọrun fun ohun Ọlọrun kọ ati ohun ti Ọlọrun jẹ, laibikita ohun ti ẹnikẹni miran sọ. Rutu tootọ niyẹn.

O ṣe ipinnu rẹ. Yala o ni lati tẹsiwaju tabi pada sẹyin ni. Awa pẹlu duro si iru ipo kan naa ni owurọ yii. Yala ki a pada sẹyin tabi ki a tẹsiwaju. Maṣe pada sẹyin laelae! Ẹ jẹ ki a tẹsiwaju. Bẹẹ ni wọn tẹsiwaju lati lọ si ilẹ-ileri si ilẹ awọn ajeji eniyan.

40 Rutu afiwe onigbagbọ bayi. Kinni onigbagbọ jẹ? Nigba ti obinrin tabi ọkunrin naa ba jade, ti ẹni naa jade kuro ninu aye, oun yoo wa si aarin awọn Kristẹni onigbagbọ. Awọn obinrin ti wọn ma n mu siga tẹlẹ, ti wọn maa n mu ọti, ti wọn ma n ta kaadi ninu awọn oriṣiriṣi ẹgbẹ gbogbo, ati bẹẹ bẹẹ lọ, ti wọn ni awọn ohun faaji, gẹgẹ bi awọn "Òpéké obinrin," ṣugbọn wayi, igbesi-aye rẹ ti yi pada! O ti ṣe ipinnu rẹ lati rin irinajo naa pẹlu Ọlọrun. Wayi, o wa de si aarin awọn eniyan kan ti wọn ko ni igbagbọ ninu ohun aye naa. Iru obinrin bẹẹ wa di ajeji. O ni lati rin gẹgẹ bi atipo. Ko mọ awọn iwa wọn, wọn jẹ ajeji si i. Ko si mọ ohun ti oun iba ṣe. Ohun ti Rutu ni lati ṣe niyẹn. Ohun ti iwọ pẹlu ni lati ṣe niyẹn. Ohun ti emi pẹlu ni lati ṣe niyẹn.

Nigba ti mo gba Kristi. Awọn ara ile mi kọ mi. Nigba ti mo gba Kristi awọn ọrẹ-kunrin ati ọrẹ-binrin mi ati gbogbo eniyan mi kọ mi. Mo wa n rin pẹlu awọn arugbo ti wọn ni Ẹmi Mimọ, ti wọn si gbagbọ ninu Ọlọrun, ti wọn si n sin! Awọn ọmọbinrin ni ile ijọsin yatọ si awọn ti mo n ba rin tẹlẹ. Irisi wọn yatọ, wọn n wu iwa ni ọna ti o yatọ, wọn ṣe ajeji, ẹru wọn si n ba mi. Wọn jẹ awọn eniyan ti wọn yatọ.

41 Ohun ti Rutu ni lati ṣe niyẹn. O ni lati jade kuro ninu awọn ohun tirẹ, lọ si ọdọ awọn ẹgbẹ eniyan miran. A yi I ni ọkan pada. O ṣe ipinnu kan. Iwọ pẹlu ṣe ipinnu kan. O si ni lati ni awọn iyan an tirẹ. Njẹ o fẹ pada si inu awọn ohun ti aye? Tabi o fẹ lati ma a tẹsiwaju pẹlu Ọlọrun?

Njẹ iwọ fẹ maa hu iwa bii ti awọn eniyan aye, ati awọn iyooku wọn. Nigba naa iwọ yoo fi ẹnu ko Jesu lẹnu, iwọ yoo wa sọ wipe o digboṣe pẹlu Kristi iwọ yoo si pada. Ṣugbọn bi o ba fẹ mu ọna rẹ pọn pẹlu awọn eniyan Ọlọrun diẹ ti a kẹgan, nigba naa di ọwọ Ọlọrun ti ko n yi pada mu. Lai bi kita ohun ti awọn eniyan aye yooku n sọ, iwọ di Ọlọrun mu sibẹ. "Ọlọrun wi bẹẹ, otitọ ni. Emi gba a gbọ. Bi emi ko tilẹ lee fi han fun aye lati ri ni igbesi aye mi, Ọlọrun sọ bẹẹ. Mo gba a gbọ. Emi yoo di i mu si bẹ!"

Ọna ti o ti ṣe pẹlu Naomi niyẹn. "Emi ko ni fi ọ silẹ. Emi yoo ba ọ lọ. Awọn eniyan rẹ yoo jẹ eniyan mi. Bi

wọn ṣe n huwa, ọna naa ni emi yoo fi ma huwa. Bi wọn ṣe n ṣe, ni emi yoo ma ṣe. Ohun ti wọn ba jẹ, ni emi yoo jẹ. Ni ibi ti o ba ku si, ni emi yoo ku si. Ni ibi ti a ba sin ọ si ni a o sin mi si. Ki Ọlọrun ki o ṣe fun mi ati ju bẹẹ lọ, bi mo ba kuna ni ibi-ki-bi. Ipinnu taara niyi. Ọlọrun n fẹ ipinnu san an lati ọwọ ijọ!

42 “Wayi, Ọlọrun, ti o ba le bukun mi lati ṣe eyi funmi, n o ṣe bayi bayi.” Eleyi ki ṣe ipinu kan.

“Ọlọrun n o fẹ mọ ohun ti o ṣe funmi, n o lọ botilẹwu ki o rii. Ti mo ba kú o dara. Iye tabi ikú, tabi ohun kohun; ti wọn ba fi mi rẹrin, ti wọn fi mi ṣe yẹ̀yẹ̀, ko jẹ nkankan. N o tẹle bi o ti lẹ wu ki o rii.” Eleyi ni ipinnu ti o mọ gẹgẹ bi eyi ti Rebeka ṣe ki o to rii Isaaki.

Awọn obi rẹ wipe, “Ẹ jẹ ki ọmọdebinrin ki o dahun, ọmọbinrin naa too ojubọ, ẹjẹ ki o dahun.'

Ọmọbinrin naa wipe, “Emi yoo lọ!” - ipinnu, ti o ṣe kiakia. O rọ̀ mọ ọn. Ohun ti Rutu ṣe niyi. Ọrpa pada.

43 Wọn n lọ ninu irinajo wọn. Rutu ninu ọkan rẹ, ko mọ ibi ti wọn nlọ, sugbọn o jẹ apẹẹrẹ ijọ. A n rinrin ajo gẹgẹ bii Abrahamu. Atipo ni ilẹ ajeji, laarin awọn eniyan ajeji. Bẹẹ lo n lọ. Nikẹyin, o de ilu ati iyara ti Naomi n mu bọ, kilo wa ri? Ṣe gbogbo awọn eniyan n fọwọ ra lẹyin ni, wipe Rutu, inu wa dun lati ri ọ?“ O ri ikorira. O ri ibi. O ri wahala.

Oniwaasu eyikeyi ti o ba sọ fun ọ pe, igbe aye kristẹni jẹ igbe-aye gbẹ̀fẹ́, yala ki o maa tan ọ jẹ tabi ki oun gan ma i tii ni iriri funra rẹ. Aye yoo korira rẹ ni. Awọn eniyan yoo si korira rẹ. Iwọ ni lati mu ọna rẹ pọn pẹlu awọn eniyan Oluwa diẹ ti a kẹgan, ki a maa fi ọ rẹrin, ki a maa fi ọ ṣe yẹyẹ, tabi ohunkohun miran, iwọ gbọdọ yatọ, A bi ọ lati orilẹ ede miran.

44 Iyawo mi (gẹgẹ bi mo ti …' a o tun un sọ lẹẹkan sii, o dabi ẹni pe yoo dara pupọ lati ṣe bẹẹ) beere lọwọ mi pe, Eeṣe ti awọn obinrin kristẹni ko fi n wọ awọn aṣọ wọnyẹn bi awọn obinrin wọnyi ṣe ma a n wọ aṣọ? Mo wipe…. O wipe,'Ọmọ orilẹ ede Amẹrika ni wa, tabi bẹẹ kọ?

Mo wipe, 'O ti o'.

'O daa, tani wa?'

Mo wipe 'Awa ki i ṣe ara Germany, ara Faranse, ara Belgiani, ara Swissi, ara Afrika, tabi ara Amẹrika. Awa kii ṣe eyikeyi ninu wọn. O ni, 'sugbọn, tani a jẹ? Mo wipe, 'kristẹni ni a jẹ.' Amerika n wuwa bi ara Amerika, ara Germany n wuwa bi ara Germany, nitori pe iyẹn jẹ ẹmi orilẹ ede wọn. Awa pẹlu ni Ẹmi orilẹ ede wa. Iyẹn ni Ẹmi Mimọ ti o n wa lati ọdọ Ọlọrun lati ọrun wa, iwọ yoo si wuwa bẹẹ. Eyi yoo mu ki o wuwa funra a rẹ gẹgẹ bi wọn ṣe n wuwa loke lọhun: Nitori pe iwọ jẹ ara aye miran.

Awa n gbe ni Amerika, otitọ ni iyẹn. Ipa ti ara niyẹn, sugbọn ọkan ti o n mu wa wuwa ti o n fi iwa wa han, jẹ lati oke wa. Awa n gbe igbesi aye wa nitori pe lati oke ni a ti bi wa wa. Gbogbo kristẹni wa lati oke, Jesu sọ wipe, 'Emi ko wa lati isalẹ, oke ni mo ti wa. Bi mo ba wa lati aye yii ni, awọn ọmọ ijọba mi iba ja fun mi, sugbọn ijọba mi jẹ ti oke. Bẹẹ gẹlẹ ni o ri pẹlu ẹni kọọkan ti a bi lati ijọba Ọlọrun wa: oke ni o ti wa.

45 Wayi, iwọ ma wo o bayi, bi a ṣe n lọ, o wa ri wipe wọn ṣe alabapade ijakulẹ, Njẹ ibi ti iwọ pẹlu ba ara rẹ niyi nigba ti o gba Ẹmi mimọ? Dajudaju o ri bẹẹ. Bẹẹ ni o ṣẹlẹ si emi naa. Wọn fi mi ṣe yẹyẹ ati ohun gbogbo rẹ

Si kiyesi, igbesi aye nira fun un igbesi aye, si ma a n nira nigba ti o ba ti di kristẹni. Nitori pe o ni lati yi ara rẹ pada kuro ni igbesi aye gbẹdẹmukẹ ati faaji aye, si aye miran ti yiya-ara-ẹni-sọtọ fun Ọlọrun. Oni lati yi igbesi aye rẹ pada si igbe aye miran ni odikeji nihin.

46 Rutu pẹlu ni lati yi igbesi aye rẹ pada kuro ni agbegbe ti o ti n ri ọpọlọpọ wẹjẹ-wẹmu ati ohun gbogbo bẹẹ, kuro ni ibi ti a ti n bọwọ fun un, si ọdọ awọn eniyan ti wọn n fi rẹrin, ti wọn n fi ṣe ẹlẹya; ni ilẹ ti o ti n ṣe ipeṣẹ́-ọka ninu oko fun ohun ti yoo jẹ. Boasi da koro ọka si inu iborun rẹ. O si gbe e lọ sile, o lọ ọ o si fi ṣe akara, ohun ati iya-ọkọ rẹ si jẹ ẹ.

Nigbati o wa nibẹ, wọn wa ri i wipe, nigba ti o n ṣe ipeṣẹ́-ọka, tabi ti o fẹ ṣe ipeṣẹ́-ọka,… Wayi Rutu ṣe ipinnu iyẹn jẹ siṣe ipinnu rẹ lati lọ sa.... bayi o ṣe ipinu rẹ.

Wayi, ohun ti o kan ni pe, o wa ni lati sin.

Ohun ti ijọ ni lati ṣe naa niyẹn. Lẹhin ijọ ti ṣe ipinnu rẹ ijọ ni lati sin. O ni lati si Ọlọrun! Ni ibamu pẹlu akọsilẹ rẹ, ni ibamu pẹlu igbẹkẹle Rẹ. Iwọ ni lati sin Ọlọrun.

47 Rutu ti o n ṣe ipinnu kan. Wayi, Rutu n sin ni abẹ́ ipinnu rẹ. [Wayi, kiyesi ni iṣẹju kan]. Wayi, Rutu lọ si oko lati sa ipeṣẹ́-ọka.

Wayi iya rẹ sọ fun un (eyi ti o jẹ Majẹmu laelae n sọ fun Majẹmu Titun, njẹ ẹ mọ), iya rẹ sọ fun un, wipe, “A wa si ni ibatan kan, orukọ rẹ si ni Boasi. Ọlọrọ ni, O si jẹ ibatan ti o sun mọ wa. Iwọ lọ, si oko rẹ boya.... ma ṣe lọ si oko ẹlomiran o, lọ si oko rẹ.”

Iyẹn jẹ bi Ẹmi Mimọ ṣe ma a n sọ fun wa pe lati ma ya lọ si inu awọn iwe ijọ kan, bii awọn katikisimu kan, ṣugbọn ki a lọ si oko Ọlọrun, iyẹn majemu laelae naa, ti iṣe Bibeli. Maṣe sọ wipe,' o ti daa, awa yoo sọ eleyi. Awa yoo si sọ eleyi fun adura kan, awa yoo ni eleyi,' Duro laara pẹlu oko na a. Lọ taara si inu rẹ nitori pe ibatan ti o sunmọ wa ni O jẹ.

48 Ọrọ Ọlọrun, iyẹn Majẹmu laelae, jẹ ibatan ti o sunmọ ni fun Majẹmu Titun. Ijọ atijọ naa jẹ iya ijọ titun (ẹ rii) iyẹn, Kristẹni, iyẹn onigbagbọ,' “Maṣe lọ si oko ẹlomiran. Duro taara ni oko rẹ. Boya ni ọjọ kan, o le ri ojurere gba lọdọ rẹ”. Ati ni ọjọ kan nigba ti Rutu wa ninu oko, ọdọ ọmọkunrin ọlọrọ naa ti orukọ rẹ n jẹ Boasi, ti o jẹ ijoye, bọrọkini kan, n kọja lọ o si ri i. Oo! nigba ti o ri i, o ni ifẹ rẹ. O ro wipe obinrin ti o dara pupọ ni eyi. O ni ifẹ rẹ, o ni ifẹ iwa rẹ. Njẹ o ranti pe o sọ pe' Emi mọ, awọn eniyan mi si mọ, pe ọmọbinrin oniwarere ni iwọ jẹ.'

O ṣe ipinnu taara, ipinnu san an. O pada wa si ihin o si gbe gẹgẹ bi o ṣe sọ wipe oun yoo ṣe'

49 Ni ọna miran ẹwẹ loni wọn wipe, “Awa mọ wipe Kristẹni ni iwọ jẹ. Awa mọ wipe eniyan Ọlọrun ni iwọ, nitori pe ko si ọkunrin ti o le ṣe awọn iṣẹ iyanu wọnyi ayaafi bi Ọlọrun ba wa pẹlu rẹ.'

Ohun ti Nikodemu sọ fun Jesu, niyẹn, o wipe, olukọni, awa mọ wipe olukọni kan ti o ti ọdọ Ọlọrun wa ni iwọ I ṣe; Ko si ọkunrin ti o le ṣe awọn nnkan ti iwọ n ṣe wonyii, ayaafi bi Ọlọrun ba wa pẹlu rẹ; nigba ti Nikodemu le e ri ti o joko nibẹ, ti o si mọ awọn ero ọkan wọn gan an yatọ.

Obinrin kan fi ọwọ kan aṣọ rẹ, O yipada o si sọ wipe, “Tani o fi ọwọ kan mi?” Gbogbo wọn ṣẹ́. O si wo ẹyin wo laarin awọn ero naa, O si wipe, “iwọ pẹlu isun ẹjẹ nibẹ, Igbagbọ rẹ ti mu ọ larada”.

O wipe, “Ko si ẹni ti o le e ṣe iyẹn ayaafi bi Ọlọrun ba wa pẹlu rẹ! Awa mọ wipe lati ọdọ Ọlọrun ni iwọ ti wa. Awa ko le e gba Ọ, nitori pe wọn yoo le wa jade lati inu ijọ.” Ẹ ri i, ẹka ajara ti o lọ naa, arakunrin West, gẹgẹ bi a ṣe n sọrọ nipa rẹ ni asalẹ ana. Wọn yoo gba ọ jade. “Ṣugbọn ni isalẹ ọkan wa awa mọ wipe, iwọ wa lati ibi ajara ojulowo naa.' Kristi ni igi ajara naa, ẹ̀ka ni awa jẹ.” Awa mọ, nitori pe a rii iye kan naa ti o wa ninu Ọlọrun, pe o wa ninu Rẹ.“

Ohun ti Boasi ri ni inu Rutu ni eyi. Ipinnu san an naa, obinrin oniwa rere kan ti o duro ni iwaju rẹ. O si ni ifẹ rẹ

50 Bayi, mo fẹ ki ẹ ṣe akiyesi, Naomi, iyẹn Ijọ atijọ, bẹrẹ si ṣalaye gbogbo awọn ofin ẹsin rẹ fun Rutu: gẹgẹ bi Majẹmu laelae ṣe jẹ ojiji fun Majẹmu Titun. Wayi, mo fẹ ki itan yi ye yin gidigidi ti majemu titun. Bayi, mo fẹ fi awọn ojiji rẹ han. Majẹmu ti laelae ṣe alaye ti titun. Ti o ba le ka. Nitori o jẹ ojiji ti Majẹmu Titun. Bayi ti mo ba nlọ si ibi ogiri yẹn, ti emi ko si ti ri ara mi, mo si ri ojiji mi, ma wa ma ri ero inu oun ti mo jẹ. Ti o ba fẹ mọ ohun ti Majẹmu Titun jẹ, nigba naa ka Majẹmu laelae iwọ yoo si ri ojiji rẹ, ẹ ri i. Nigba yi ni Majẹmu Titun bẹrẹ, iwọ yoo wa, wipe, “Eeṣe, dajudaju, ohun naa niyi.” Iwe Heberu, Paulu pada sẹhin o si ṣe alaye rẹ.

51 Wayi, ṣe akiyesi rẹ daradara bayi, nigba ti Rutu sọ wipe.... tabi nigba ti Naomi sọ fun Rutu, pe, ti o wipe “ọkunrin naa jẹ ibatan wa. Ti o ba le ri ore-ọfẹ gba lọdọ rẹ, iwọ yoo ni isimi.” (Oo, akiika!) “Bayi ti o ba ri ore-ọfẹ gba ni ọdọ rẹ iwọ yoo ni isimi.” Boasi duro fun Kristi, ọkunrin Ọlọrọ naa ẹni ti o jẹ arole ohun gbogbo, ti Oluwa ikore. Oo akiika! Eeṣe, ani gẹgẹ bi, Boasi si wa ti o gun kẹkẹ ẹsin wa si bẹ o n wo gbogbo ayika ọgba, oju rẹ si ri Rutu. Oun ni ọ̀gá. Oun ni Oluwa Ikore naa. Rutu wa ri ojurere gba ni iwaju rẹ (Boasi).

Ohun ti ijọ n ṣe gẹlẹ niyi loni. Nigbati Oluwa Ikore n kọja lọ, Oluwa ri awọn ile nlanla awọn ile olori ṣonṣo tempili,

Awọn ẹgbẹ akọrin ti a kọ daradara. Oun n wa awọn aladori ẹnikọọkan! Awọn Ọkunrin ati obinrin ti wọn ti fi ara won ji Kristi, ti wọn yaa ara wọn sọtọ fun iṣẹ Ọlọrun. Ti wọn ṣe awọn ipinnu taara, ipinnu san an fun Kristi, ti wọn ya ara wọn sọtọ fun isin Rẹ “Ọlọrun emi gba a gbọ! Mo gba gbogbo Ọrọ rẹ Kọọkan gbọ.” Nigba ti Ọrọ Rẹ ba sọ ohunkohun, emi yoo duro taara pẹlu rẹ. Ọrọ rẹ niyẹn. Mo gba gbogbo Ọrọ rẹ gbọ. Ọrọ rẹ kọọkan gbọ'. Ohun ti Kristi n wa niyẹn, Oluwa Ikore. Awọn ẹni ti o fẹ fun ni Ẹmi mimọ naa ni awọn ti ebi n pa. Awọn ti o pongbẹ ni. “Alabukunfun ni ẹyin nigba ti ebi ba n pa yin, ti oungbe si ngbẹ yin: nitori a o kun yin. Oun n gbiyanju lati ri ijọ naa ni oni.

52 Bayi, nigba naa, a sọ fun Rutu ki o ṣe ohun itiju kan, oun si ti ṣetan lati ṣe bẹẹ nitori pe o ti ṣe ipinnu rẹ. Iru apẹẹrẹ onigbagbọ wo ni Rutu jẹ. Iru apẹẹrẹ pipe wo ni eyi!

Naomi, ti I ṣe ijọ atijọ naa, wipe, 'Lọ ni asalẹ yi, akoko ikore baali ni! Oo, ero ti o rẹwa ti a lee so ara wa

taara mọ nibẹ ni eyi.

Naomi ati Rutu de ni akoko ikore ọka baali gẹlẹ. Akoko ọka baali jẹ akoko ounjẹ-akoko ti a n I bọ ni, ounjẹ ti a ṣẹṣẹ pese. Ijọ ni opin ọjọ wọnyi, ti o ti lọ ninu ẹgbẹwa ọdun ti ikoni iboriṣa ati ohun gbogbo bẹẹ ti wa de ni akoko ikore ọka-baali, ti I ṣe igbe-aye titun, ounjẹ tuntun, oyin lati ọrun wa. (Russell sọrọ nipa akara ti ao fi oyin din!) Ohun gan an niyi! Akara iye. Awọn baba yin jẹ mana wọn si ku. Sugbọn Emi ni akara iye ti o ti ọdọ Ọlọrun wa lati ọrun. Bi eniyan kan ba jẹ ninu akara yi, oun ki yoo ku mọ laelae.' Ni opin ọjọ yi, a si mu ijọ wọle wa bayi ni akoko ikore ọka-baali.

53 Rutu, ọmọ ẹya Alaikọla kan, ni a le jade, ti a ti I danu, a si ti mu un wọle bayi gẹgẹ bi (a ni lati tẹwo gba a gẹgẹ bi iyawo Kristi) o wọle wa ni akoko ọka baali.

O wipe, “Wayi i, wọ aṣọ rẹ si ọrun rẹ.” Ko wipe, “Bọ aṣọ rẹ kuro ni ọrun rẹ.” Bawo ni eyi ṣe yatọ to si ti oni. “Wọ aṣọ rẹ si ọrun rẹ nigba ti iwọ ba lọ pade rẹ. Oun yoo lọ fẹ ọka barle ni alẹ oni. Sọkalẹ lọ ki o si wọ aṣọ rẹ si ọrun rẹ. Bo ara rẹ daadaa, lati lọ pade rẹ.

Loni, wọn ko fẹ wọ aṣọ. “Wọ aṣọ si ọrun rẹ daadaa. Sọkalẹ lọ si ọdọ rẹ nitori pe o yoo fẹ ọka-barle. Lẹyinnaa iwọ ṣe ami si ibi ti yoo sun si.” Njẹ iwọ ṣe iyẹn? Ni Gọlgọta! Ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin, mo ṣe ami ni ọkan mi nipa ibi ti O ti fi Ẹmi Rẹ le lẹ ki O lee gba mi. “Kiyesi ibi naa ti o sun si. Ṣe akiyesi ibi ti o sun si.” Ohun ti onigbagbọ kọọkan yẹ ki o ṣe niyẹn. Ṣe akiyesi Ohun ti O ti ṣe fun ọ. Iwaasu Ọjọ Aiku ti o kọja lori, “Ibẹwo si Kalfari.” Ṣe akiyesi ohun ti Kristi ṣe fun ọ.

54 Naomi sọ wipe, “Sàmì si ibi ti Boasi sun si. Nigba ti o ba ti fi ara le ilẹ lati sun (lati simi) iwọ lọ ki o si sun si ibi ẹsẹ rẹ.” Ki i ṣe ni ibi ori rẹ; ẹsẹ rẹ! - alaiyẹ. “Lẹyinnaa, mu aṣọ ibora rẹ, ki o faa le ori ara rẹ.” Njẹ iyẹn ye yin? Kaaṣa, mo mọ pe iwọ le e ro wipe emi jẹ alakata-kiti ẹsin, ṣugbọn iyẹn tẹ mi lọrun gẹlẹ, iyẹn Ẹmi Ọlọrun. Ṣe akiyesi ibi ti O sun si.... ni Kalfari; ni ibi ti O ti sun si inu iboji naa; ni Gẹtisimani. Ṣe akiyesi rẹ, fa lọ si ibi ẹsẹ Rẹ, ki o si sun si ibẹ, ki o si ku si ara rẹ, ẹ ri i. Bi ọrọ naa ṣe ri ni iyẹn. Fi aṣọ rẹ bo ara rẹ. O wipe, “Aṣọ rẹ naa,” oun ti obinrin naa pe e niyẹn.

Rutu si sọ pe, “Ohun ti iwọ ba sọ fun mi ni emi yoo ṣe.”

Oo, ipinnu sàn án kan fun onigbagbọ kan kọ ni eyi! “Ohun ti Bibeli ba sọ, iyẹn ni emi yoo ṣe. O sọ wipe, 'Ẹ ronupiwada, ki a si baptisi yin ni orukọ Jesu Kristi,' Emi yoo ṣe bẹẹ. Bi o ba sọ pe, 'Ẹ lọ si inu gbogbo aye ki ẹ si lọ waasu ihinrere, emi yoo ṣe bẹẹ. Bi o ba sọ pe.... ohun yoowu ti o ba sọ, 'Jesu Kristi ọkan ni àná, ọkan ni oni ati ọkan titi ayeraye.' Ohunkohun ti o ba sọ fun mi pe ki n ṣe, emi yoo ṣe e.” Ẹ ri i, eyi jẹ ijọ ti o n gba aṣẹ lati inu Ọrọ Ọlọrun. O n sun silẹ.

55 Wayi, ranti, ohun itiju ni iyẹn jẹ fun ọdọbinrin opó naa lati lọ sun si ẹgbẹ ọkunrin yii, ni ibi ẹsẹ rẹ. Ohun itiju loju awọn eniyan ti aye! Oo, njẹ iwọ le e fi ara da a? Ohun ni yi.

Wo o! Wo o, bi o ṣe jẹ niyi! Ijọ naa, awọn ọdọbinrin naa, awọn ọdọkunrin, awọn arugbo tabi awọn ọdọ, ni a sọ fun wipe ki wọn ya ara wọn sọtọ kuro ninu aye, ki wọn si wa si ibi kan, ijọba ti Ẹmi Mimọ kan, eyi ti o jẹ ohun itiju si aye. Ni inu ọkan wọn, wọn mọ ohun ti ohun yii tumọ si. Ṣugbọn ni oju awọn eniyan aye wọn jẹ awọn alakata-kiti ẹsin, wọn jẹ awọn agbarayilẹ mimọ tabi iru ohun kan bẹẹ, orukọ itiju kan. Ṣugbọn a sọ fun ijọ ki o ṣe bẹẹ. Njẹ iwọ n fẹ lati sami si ibi naa, ki o si sun si ibẹ? Jẹ ki aye pe ọ ni ohunkohun ti wọn ba fẹ pe ọ.

Orin atijọ kan lọ bayi pe:

Emi ti bẹrẹ irinajo naa pẹlu Jesu nikan

(Njẹ iwọ ri i?)

Ki emi ni irọri okuta bi i ti Jesu

Emi yoo mu ọna mi pọn pẹlu awọn

Eniyan Oluwa diẹ ti a ti kẹgan

Emi ti bẹrẹ pẹlu Jesu, emi yoo rin

Irin ajo naa de opin.

56 Bi o ṣe ri niyẹn. Ohunkohun.... Emi yoo san owo itanran naa ohun-yoo-wu ti awọn iyooku n ṣe. Bi o ba jẹ itiju ni, bi o ba jẹ ki n padanu ile ni, ki n padanu ẹbi ni, gbogbo awọn ẹlẹgbẹ mi, awọn ọrẹ-binrin, awọn ọrẹ-kunrin, ohunkohun ti o lee jasi, emi yoo lọ ni emi-ni-kan. Emi yoo rin ọna naa! Bi aladugbo mi ba wipe

agbarayilẹ-mimọ ni mo jẹ, tabi ọmọ-ijọ Afi-ede fọ ni mi, tabi alakatakiti-ẹsin ni mi, emi ko bikita ohunkohun ti wọn lee sọ. Eyi ko jẹ nnkan kan si mi, mo ti bẹrẹ pẹlu Rẹ, mo ti ṣe ipinnu taara, emi yoo rin irinajo naa de opin ni.

57 Wayi, oun ni ẹnikan naa ti o lee fun un ni isimi kuro lọwọ aarẹ-oko ti ipeṣẹ́-ọka naa. Haa, o si dun gan an ni o, nigba ti Boasi, nigba ti o wa a ri ninu oko naa (emi ko lee padanu eleyi), Boasi wa a ri ninu oko, o wipe, “Woo, o sọ pe, ”Tani ọ?“

O wipe, “Orukọ mi ni Rutu.”

“Oo, ara Moabu ti o wa ṣe atipo pẹlu wa.”

“Bẹẹni”

“Mo ti gburo rẹ. Maṣe lọ si oko-ọka miran”

Mo nifẹ eleyi. “Maṣe maa bẹ kaa-kiri ki o ni o n ṣe iṣẹ ijere-ọkan. Joko taara nihin ninu oko-ọka mi. Duro ti awọn ti o jẹ temi.” O ni ifẹ rẹ. “Duro nihin! Duro ti mi! Maṣe ma a sare si lọ sihin sọhun. Duro nihin.”

Bi iwọ ba gba iṣẹ ti Ọrọ Ọlọrun ti oni gbọ, sọrọ̣ mọ ọn, ẹ rii. Ohunkohun ti owo itanran naa lee jẹ, duro taara pẹlu rẹ. Maa tẹsiwaju. Bi o ba tumọ si ki o ṣẹ́ ara rẹ nipa eyi, iyẹn, ati omiran, mo ni lati fi ọti-mimu mi silẹ, mo ni lati fi ole jija mi silẹ, irọ pipa mi; sibẹ emi yoo duro taara pẹlu rẹ.“ ẹ rii.

58 O tun sọ lẹẹkan sii.... O wipe, “Wọn ko ni yọ ọ lẹnu, nitori mo ti paṣẹ fun awọn ọdọkunrin naa lati ma ri ọ fin.” Amin. Mo nifẹ eleyi: aabo rẹ. Tani o sọ iyẹn? Oluwa Ikore na a

“Sọra. Maṣe fi ọwọ kan ẹni ami-ororo mi; ma si ṣe ṣe awọn woliii mi ni ibi.” Ṣe bẹẹ ni? “Nitori, lootọ ni mo wi fun un yin, yoo san fun un yin ki a so ọlọ mọ yin lọrun ki a si sọ yin si isalẹ okun.... ani lati ṣẹ ẹnikan ti o kere julọ ninu awọn temi kekere wọnyii.” Ṣe bẹẹ ni. “Maṣe dabaa lati mu ohun ikọṣẹ wa fun wọn.” (“Mo ti paṣẹ fun wọn lati ma fi ọwọ kan ọ.”). Oo, kiyesi awọn aye ti wọn jẹ oninuni-bini naa. Wakati wọn n bọ.

59 Nigba naa ni o lọ ba awọn ọmọkunrin naa, awọn iyooku, o wipe, “Wayi, o n ṣe ipeṣẹ́-ọka fun iye. Wayi, ẹyin olukore, iyẹn ẹyin angẹli....: Ni ọrọ miran ẹwẹ, (Ohun ti wọn jẹ niyẹn). O wipe, ”Mo fẹ ki ẹyin angẹli, ẹyin olukore, pe lẹẹkọọkan ki ẹ mọnmọ da ẹkunwọ ọka silẹ. Ẹ maṣe jẹ ki wahala na a pọ pupọ ju fun un. Ṣugbọn lẹẹkọọkan, ẹ jẹ ki o gbọ iwaasu kan ti o dara. Ẹ jẹ ki agbara Ẹmi Mimọ kan ti o dara wa si ori rẹ lẹẹkọọkan, ki o lee mọ wipe Emi si wa nibẹ pẹlu. Ẹ ṣe awọn iṣẹ ara tabi iṣẹ-iyanu kan han, ki o lee mọ wipe mo si wa laarin rẹ.“ Bi o ṣe ri niyẹn.

Njẹ iwọ ko ni fẹ rii awọn ẹkunwọ ibukun naa? Mo ro wipe awa yoo ri diẹ ninu wọn ni owurọ yii, ṣe ẹyin ko ro bẹẹ? Ẹkunwọ ọka-barle ti a ṣẹṣẹ kore rẹ, ki Oluwa ṣe ohun kan ti O maa n ṣe, ohun kan ti awa mọ wipe O maa n ṣe. Oun ni Oluwa ikore naa. Oun ni Ẹnikan naa ti o le da ẹkunwọ ibukun naa silẹ. Mo ti paṣẹ fun awọn angẹli naa lati sọkalẹ lọ si inu ipade iwaasu naa ni owurọ yii. Mo fẹ ki wọn ṣe awọn ohun kan, ohun kan ni pato. Emi ti paṣẹ fun wọn! Wọn yoo si ṣe e.“ Akiika.

60 Wayi, nihin o ni lati mu mọ-ara ipa ti itiju naa, lati sun silẹ, iyẹn ki awọn eniyan pe e ni ohunkohun ti wọn ba fẹ lati pe e ni aṣẹwo, ṣe o mọ? A lee pe e ni obinrin oniwa-aimọ, sibẹ ẹda ti o jẹ kọ ni iyẹn. Ṣugbọn, o sa a n tẹle gẹlẹ ofin ti a gbe kalẹ fun un ni. Nitori na o sọkalẹ lọ o si fi ibọra ọkunrin naa bo ara rẹ. Nibo ni o lọ? O lọ si inu iboji naa. Ni bo ni ọmọbinrin naa lọ? Nibi ti oun ti n simi ni.

Nibẹ ni mo ti ri I:

NIbẹ ni ibi agbelebu, nibi ti Olugbala mi ti ku,

Nibẹ fun mọ kigbe fun iwẹnumọ kuro

ninu ẹṣẹ,

Nibẹ ni a sami ẹjẹ na a si ọkan mi

Orisun kan wa ki a kun pẹlu ẹjẹ

Eyi ti a fa jade lati inu isan Immanuẹli

Nibi ti ẹlẹṣẹ ti n luwẹ ninu isun naa.

Ti o si n padanu gbogbo ebi ti abawọn ẹṣẹ rẹ.

61 Sami si ibi na ti O sun si. Ki o si sun sibẹ pẹlu Rẹ. Njẹ iwọ ṣetan lati lọ si Kalfari ni owurọ yii, gẹgẹ bi mo

ṣe sọ ni Ọjọ Aiku ti o kọja? Njẹ iwọ ti mu ara rẹ wa si ibi naa, nibi ti a ti kan Jesu mọ agbelebu?

“Oo, awa mọ riri iyẹn.” Ṣugbọn bawo ni ti ikanmọ agbelebu rẹ? Njẹ o ṣetan lati rin ọna naa pẹlu orukọ itiju bi I pe ki a pe ọ ni agbara-yilẹ mimọ, alakatakiti ẹsin, tabi ohunkohun ti o lee jẹ. Ohunkohun ti owo itanran naa lee jẹ?

Njẹ o ti sami si ibi naa, ki o lee lọ ki o si sun si ibẹ pẹlu Rẹ, ki o wipe, “Oluwa emi ha kọ niyi?” Lẹyin naa, kinni o kan? Fa aṣọ ibora ti o wa lara Rẹ, ki o fi bo ara rẹ.

62 Nigba kan obinrin kan sọ fun Oluwa wa pe, “Oluwa, gba a bẹẹ fun awọn ọmọkunrin mi mejeeji ki ọkan joko si ọwọ ọtun Rẹ, ki ekeji si joko ni ọwọ osi Rẹ ninu ijọba naa.”

O si da a lohun wipe, “Njẹ iwọ lee mu ninu ife na a ti Emi yoo mu?” Iyẹn jẹ inunibini ti o korò naa

“Bẹẹni”

“Njẹ iwọ le e ṣe iru itẹbọmi kan naa ti a o fi ṣe itẹbọmi fun Mi?” Ki o sun silẹ, ki o fa aṣọ ibora mi bo ara rẹ. A gbe Elija lọ si oke. Elija si ju aṣọ amure rẹ kan naa ti o ni silẹ lati fi bo Elisa pẹlu ilọpo-meji ti Ẹmi rẹ. Ohun kan naa ni, o sa a jẹ ilọpo meji ni. Agbara kan naa ni, ko ju.... ko ju bẹẹ lọ, o saa jẹ ilọpo meji rẹ ni.

63 Gẹgẹ bii Mose, nigbati o rẹ ẹ, baba iyawo rẹ sọ fun un pe, o wipe, “Iwọ n lo ara rẹ pupọ ju. Gbadura ki Ọlọrun ki O fi ẹmi rẹ le ori awọn miran,” O si gbadura.

O mu Ẹmi rẹ wa si ori awọn aadọrin eniyan miran, awọn aadọrin naa si bẹrẹ sii sọ asọtẹlẹ. Wọn ko ni agbara ti o pọ ju eyi ti wọn ti ni tẹlẹ lọ, ṣugbọn wọn gba irin-iṣẹ pupọ ju eyi ti wọn ni tẹlẹ lọ, o tan. Wọn saa ni irin-iṣẹ pupọ sii ni.

Bi o ṣe ri ni oni niyẹn. Ẹnikanṣoṣo ko le e ṣe iṣẹ naa. Ọlọrun ni awọn irin-iṣẹ Rẹ ti O fi n ṣi ṣẹ ni ibi gbogbo, ṣugbọn o jẹ agbara kan naa. Agbara kan naa ni, Ẹmi Mimọ kan na a ni, Jesu kan naa ni.

64 Wayi.... mu ibora ti o nipọn naa, Ẹmi Mimọ naa. Nigba ti o ku si ara rẹ, sami si ibi ti o ku si.... n ibi ti o sun lati simi si, nigba naa ni o sun si ilẹ, o si mu aṣọ ibora ti o nipọn naa eyi ti ọkunrin naa fi bora, o si fa a lati fi bo ara rẹ. Ọkunrin naa si ji, o si wipe, “Tani o wa ni ibẹ?”

Oun si wipe, “Rutu ni mi, ara Moabu, iranṣẹ-binrin rẹ.”

Ọkunrin naa si dide joko. O wipe, “Mo woye, mo si mọ wipe obinrin oniwa-rere ni o jẹ.” Amin. Njẹ eyi ko mu ki ara rẹ ki o ṣẹ giiri diẹ, l'a ọkan rẹ ja? “obinrin oniwa-rere ni o jẹ!”

65 Ki wa ni o fi dahun? “Ṣugbọn iwọ ni ibatan ti o sunmọ wa.” Amin. “Iwọ ni ibatan ti o sunmọ wa. Iwọ lee ṣe e fun mi. Iwọ lee fun mi ni isimi. Mo ti wa si ihin, mo ti sun silẹ nihin, ki i ṣe gẹgẹ bi obinrin oniwa-ibajẹ kan. Mo sun silẹ nihin, ki i ṣe lati jẹ alaṣehan kan [ki i ṣe lati fi han awọn eniyan pe, ”mo lee fi ede fọ,“ ki i ṣe lati fi han awọn eniyan pe, mo le e jo ninu Ẹmi, ki i ṣe ki n le fi han awọn eniyan pe, ”mo lee pa ariwo“], ṣugbọn mo wa si ihin nitori pe iwọ ni ibatan ti o sunmọ wa. Ki i ṣe lati fi han wipe mo ni agbara lati lee ṣe nnkan ti o tobi; ṣugbọn ibatan wa ni iwọ jẹ. Mo wa nitori wipe, ibatan ti o sunmọ wa kan ni iwọ jẹ, iwọ si ni ẹni kan naa ti o lee ra mi pada.” Iwọ wo iwuwasi ẹni kan ti a ti yi ọkan rẹ pada si Kristi tabi si ijọ ni? Ẹ rii, njẹ iwọ ri? “Ibatan ti o sunmọ wa ni o jẹ.”

Oun si wipe, “Obinrin oniwa-rere ni iwọ jẹ, Ibatan ti o si sunmọ ọ ni emi. Wayi, da aṣọ bo ara rẹ, ki o si sun titi ilẹ yoo fi mọ. Saa fi aṣọ ibora ti o nipọn naa bo ara rẹ, ibatan rẹ ni mo jẹ. Sun sibẹ titi ilẹ yoo fi mọ, saa maa simi.” Amin, amin. “Ibatan rẹ ti o sunmọ ọ ni emi. Maa simi!” Amin.

66 Nigba ti owurọ si de, ni afẹrẹmọju, o ko ọpọlọpọ ọka barle (mo gbagbọ wipe oṣuwọn mẹfa ni) o si da si inu iborun rẹ kekere naa, o si pada si ile. Naomi si wipe, “Ọmọbinrin mi.”

Lẹyin ti o ti dide kuro ni ibi ori pẹpẹ, ti o si pada o ni, “Bayi mama kinni yoo wa ṣẹlẹ? Kinni yoo wa ṣẹlẹ bayi?”

“Simi!” (Amin) “Rutu simi, nitori pe ara ọkunrin naa ko ni balẹ titi ti yoo fi san ẹkunrẹrẹ owo itanran ti irapada.” Amin, amin Ipo yii taara ni mo duro si. Amin. Oun ki yoo simi ti yoo ba fi san oye owo irapada naa lẹkunrẹrẹ lati ra ọ pada, ohun gbogbo ti iwọ ti padanu ri, ohun gbogbo ti iwọ jẹ

67 Wayi, ranti, ofin irapada naa (gẹgẹ bi awa ti n wa si.... bi a ti n sunmọ opin isin na a bayi), gbogbo ofin irapada ni eyi: Ki ọkunrin kan to lee ra dukia kan ti a ti padanu pada, o ni lati jẹ ibatan ti o sunmọ ni naa. ohun ti o kan ni pe, o ni lati jẹ ẹni iduro-ṣinṣin kan, o si ni lati jẹ olododo kan, lati lee ṣe e. Ati lẹyin naa o ni lati jẹ ẹni ti o ni owo pupọ to lati lee rapada. O si gbọdọ ṣe ijẹri ita-gbangba pe oun ti ra a. Lẹyin naa lọ, dukia naa ti di

tirẹ.

Nitori naa wo o. Boasi duro fun Kristi. Wayi, Rutu duro fun ijọ, iwọ, onigbagbọ naa. Ati bayi ninu Majẹmu Laelae, ọna kanṣoṣo ti Ọlọrun fi lee wa lati rapada ohun kan ti a ti padanu, O ni lati di ibatan ti O sunmọ eniyan. Ati ọna kanṣoṣo ti Ọlọrun fi lee di ibatan fun eniyan ni ki O di ọkan lara wọn. Amin.

68 Mo tako Billy Graham tabi ẹnikẹni ti o jẹ olukọni nipa Ọlọrun mẹtalọkan, lori eyi pe ẹni mẹta ni o wa ninu Ọlọrun kan. Mo gbagbọ ninu mẹtalọkan ni tootọ, ṣugbọn ki i ṣe ni ọna ti awọn fi gba a gbọ, pe wọn jẹ awọn mẹta. Ọkan ni wọn jẹ. Itan yii nihin nikan, bi ko ba tilẹ si ohun miran fi idi rẹ ọrọ yii mulẹ.

Ọlọrun di eniyan! O ni lati jẹ ibatan. Ko si lee jẹ Ọlọrun ki O si jẹ awa ẹlẹṣẹ nigba kan naa (Awọn ẹda ti iṣẹda Rẹ, awọn ẹda ti O da lati inu iṣẹda Rẹ), nitori a ko le e jẹ ibatan nibẹ bẹẹ. Nitori naa Ọlọrun di eniyan, ki eniyan lee di Ọlọrun. Amin

69 Awa ti awa jẹ eniyan, awa ẹlẹṣẹ, Ọlọrun di ẹlẹṣẹ, O ko ẹṣẹ wa wa si ori ara Rẹ. Ẹni ti ko mọ ẹṣẹ, sibẹ O di ẹlẹṣẹ nitori a di ẹṣẹ wa lẹ E lori, ki Oun di emi, ki emi lee di Oun, ẹ rii. Oun di ẹlẹṣẹ, ki emi lee di ọmọ Ọlọrun. Oun di ẹlẹṣẹ, ki emi lee di ọmọ Ọlọrun. Wayi awa ti di awọn ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun nitori pe a sọ Ọlọrun di ibatan wa! Nigba ti o gbe irisi ẹran ara awa eniyan wọ, ti a bi I nipaṣẹ obinrin kan. Ọlọrun! Ki i ṣe ẹlomiran; ani Ọlọrun funra ara Rẹ. Iwe Timoti kinni 3:16 wipe, "Laisi ariyanjiyan titobi ni ijinlẹ ẹni ti Ọlọrun jẹ. Nitori a fi Ọlọrun han ninu ara." Ọlọrun! "Ni atetekọṣe ni Ọrọ wa, Ọrọ naa si wa pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si ni Ọrọ naa. Ọrọ yii si di eniyan."

70 Ọrọ yii di eniyan ẹlẹran ara, O di ibatan, O di ọkunrin kan. (Oo!) O di iku, ki o lee jẹ nipasẹ iku Rẹ ki emi lee di alaaye. O di ẹlẹṣẹ, ki o lee jẹ nipasẹ ododo Rẹ ki emi lee di.... ki n lee ni iye. Oun di otoṣi, ki emi nipa aini Rẹ, ki a lee sọ mi di Ọlọrọ. Oun di ẹni ti emi jẹ, ki emi, nipasẹ oore-ọfẹ Rẹ, lee di ẹni ti Oun jẹ. Oo Akiika! Ki a wa sọrọ nipa awọn agbara Ọlọrun. Ohun ti Iwe Mimọ sọ niyẹn.

Ki awa lee jẹ.... Iru ifẹ nla ni eyi ti Baba ni.... da le wa lori. Ti a da le wa lori, ki o lee jẹwọ pe awa ti a jẹ ẹlẹṣẹ nigba kan ri, awa alejo, ti a ti ṣako lọ kuro lọdọ Ọlọrun, ki a lee fa wa sunmọ Ọlọrun to bẹẹ ti a fi wa di ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun - a kii ṣe iranṣẹ mọ. Ijọ awọn ẹya alaikọla ko fi igba kan jẹ iranṣẹ. Rara o ti o! Ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun ni awọn ẹya Alaikọla jẹ, Ẹyin ti ẹ ti gba Ẹmi Mimọ jẹ ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun. Wayi, ti o ba jẹ ara awọn ẹgbẹ Ọrpa ti ẹ fi Ọlọrun silẹ - Ṣugbọn ti ẹ ba ti gbagbọ de ibi ti ẹ ti gba Ẹmi Mimọ, ẹ ti di ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun.

71 Wayi, ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun, awọn wo ni wọn ni agbara ti o ga julọ niwaju Ọlọrun? Kinni angẹli jẹ? Iranṣẹ ni angẹli. Ṣe bẹẹ ni? Iranṣẹ ni wọn. Kinni iwọ? Ọmọ Rẹ ọkunrin tabi obinrin, Ta wa ni o ni agbara ti o ga julọ ni ọrun, nigba naa? Ẹlẹṣẹ kan ti a ti gbala nipa oore-ọfẹ, tabi olori angẹli kan ti o n duro ni ọwọ ọtun Rẹ? Ẹlẹṣẹ kan ti a ti gbala nipa oore-ọfẹ ni aṣẹ ni ọrun ju olori angẹli ti o duro ni ẹgbẹ Rẹ laini ẹṣẹ! Nitori wipe o jẹ ọmọ Rẹ. Ni ọpọ igba awa ma a n gbagbe bi a ṣe de ipo ti a de. Nigba ti Ọlọrun....

Oo iru ifẹ iyebiye ti Baba fi fun Iran Adamu ti o ti ṣubu.

O fun wa ni Ọmọ Rẹ kanṣoṣo lati jiya ati lati ra wa pada nipa Oore-Ọfẹ Rẹ.

(Oo, bawo ni awa yoo ṣe mọ rara?)

Laarin apata ti n ya ati oju ọrun ti o ṣokunkun

Olugbala mi tẹ ori Rẹ ba O si ku;

Aṣọ ikele ti o si fi ọna naa han

Si ayọ Ọmọ ati ọjọ ailopin.

Lori Kristi apata naa ni mo duro;

Gbogbo ilẹ ti o ku, iyanrin ni;

Nigba ti mo ro ti agbelebu iyanu naa

Nibi ti Ọmọ Alade Ogo ti ku,

Mo ka gbogbo ẹṣẹ mi si asan,

(Bẹẹ gẹlẹ ni)

Ẹnikan sọ pe:

Ni wiwa laaye Rẹ, O fẹ

Ni kiku Rẹ O gba mi la.

Ni sinsin Rẹ, o ru ẹṣẹ mi jina rere;

Ni jijinde Rẹ O da mi lare titi laelae.

Ni ọjọ kan, O n pada a bọ-Ọjọ ologo naa!

72 Eyi ti jẹ ọrọ pataki ti ijọ, O jẹ ọna ti o fi n wo nnkan. O ti jẹ ọkan rẹ. Ẹjẹ ibatan olurapada ti wẹ ile-aye yii; lati ra iran Adamu ti o ti ṣubu pada.

Kiyesi i nihin ohun ti O jẹ niyẹn, Ibatan Oluranipada. Wayi, ohun akọkọ: o ni lati jẹ ọkunrin ti o kun oju oṣuwọn ju Kristi lọ, ju Jesu lọ? Lẹyin naa ohun miran ni pe: O ni lati ni owo. O lati ni ipá lati lee ṣe e. Oun ni o ni awọn ọrun. O fi da ni loju pe Oun ni o ni wọn. O le e mu iṣu akara marun ati ẹja wẹwẹ meji ki o si fi bọ egbẹrun marun eniyan, O siko ajẹku ounjẹ naa ti o jẹ agbọn marun. O fa omi jade lati inu kanga o si sọ ọ di waini. O le e mu ẹja jade lati inu ókun, O si mu owo ẹyọ wura jade lati ẹnu rẹ. Amin.

Oun ko jẹ.... Ṣugbọn O di otoṣi, ko si ni ibi ti yoo fi ori Rẹ le. O wa di ibatan kan. Ki i ṣe ibatan kan fun awọn ọlọrọ, ibatan kan fun gbogbo eniyan. O gba ipo ti olurapada kan.

73 Ki wa ni O ni lati ṣe? O ni lati ṣe ijẹri ita gbangba kan. Ni owurọ ọjọ keji, Rutu wipe.... tabi, Naomi wipe, “Rutu simi. Ohun gbogbo yoo dara bayi, nitori pe o ti ri oore-ọfẹ gba ni iwaju rẹ.”

Ọlọrun jẹ ki eyi ṣẹlẹ si mi. Jẹ ki n ri oore-ọfẹ gba ni iwaju Rẹ. Nigba naa, nigba ti ilẹ ba mọ:

Nigba ti ipe Oluwa ba dun, ti ko si si Akoko mọ

Nigba ti owurọ mọ, ọjọ ainipẹkun ti

O mọlẹ ti o si rẹwa;

Nigba ti awọn ẹni igbala ni aye yoo ba

Ko ara jọ pọ ni odi keji ni bebe naa,

Nigba ti a ba n pe orukọ loke ni

Odi keji lọhun, emi yoo wa nibẹ.

(A n simi bayi, a n duro de ẹkun rẹrẹ irapada naa.)

74 Kiyesi i, “Mo ni in, itọwo rẹ naa, bayi. Mo ti wa si ile pẹlu ẹkun aṣọ iborun ti o kun fun ọka baali. Mo de ibẹ.... O fi fun un, o wọn ọn jade, oṣuwọn mẹfa. ”Mẹfa“ tumọ si ẹgbẹrun ọdun mẹfa ti aye yii ti fi wa! Mẹfa jẹ ọjọ eniyan. A da eniyan ni ọjọ kẹfa. Ẹgbẹrun ọdun mẹfa ti o ni lati wa ti a ti da aye, ni ẹgbẹrun ọdun keje, Ọlọrun simi. Ẹgbẹrun ọdun mẹfa ni ijọ ti ṣe laalaa lodi si ẹṣẹ pẹlu agbara Ọlọrun nipa awọn iṣu akara ti ọka baali naa, lẹyin naa ni yoo lọ sinu isimi ainipẹkun. Isimi, duro. Oṣuwọn mẹfa ti iyẹfun ọka baali daradara ni o wọn sibẹ, lati fun un ni okun titi yoo fi di akoko ẹkunrẹrẹ irapada. Inu mi dun pupọ lati gbadun eleyi.

75 Wayi i, ni kiakia, ẹ jẹ ki a lọ si opin iwaasu naa. Wayi, a wa ri wipe bayi, pe ni owurọ ọjọ keji nigba ti Rutu ji, inu rẹ dun pupọ, o n duro, lẹyin naa ni ọkunrin naa de. O lọ.... Ibatan miran tun wa, ti o jẹ wipe o tun ni ẹtọ ni akoko lori obinrin naa. Njẹ mo ni akoko lati lọ si inu iyẹn? O daa, ni iṣẹju kan a mu abala rẹ kan wa lọnakọna.

Ẹni ti o kan naa ninu afiwe yii, ti o ni ẹtọ lori rẹ, ni eṣu, nitori pe o ti dẹṣẹ. Ati ni akọkọ iwọ jẹ tirẹ, nitori pe o jẹ dukia rẹ. Nitori a “bi ọ ninu ẹṣẹ, a mọ ọ ninu aiṣedeede, o wa si aye o n parọ.” Oun ko si lee ṣe iṣẹ irapada naa. O rii, Oun ko lee ra ni pada. Nitori naa Kristi wa, a si so Ọ di eniyan lati ko ẹṣẹ wa lọ, lati rawa pada! Njẹ eyi ye ọ bi? Ọkunrin keji ko si lee ṣe e. Eṣu ko lee ku fun ẹṣẹ, nitori wipe oun gan an ni oludibajẹ naa, gan an ti o da ẹṣẹ silẹ. O rii, ko lee ṣe e, eyi yoo ba ogun-ini rẹ je, iyẹn ẹnikeji naa. Satani ko si ni fẹ ba ogun ibi rẹ jẹ nitori pe eṣu ni. Ko lee di eṣu miran lati mu eṣu akọkọ kuro. Ko lee di ẹṣẹ, nitori pe ẹṣẹ na a ni tẹlẹ. Ṣugbọn Kristi ti o jẹ alailẹṣẹ di ẹlẹṣẹ. O ni agbara lati ra wa pada! Alleluya, a ti ra wa pada! A ti ra wa pada; eyi jasi lati “mu wa pada.” A ti ra wa pada.

76 Nitori naa ni owurọ ọjọ keji, O n lati ṣe ijẹri ita gbangba. O wa o si lọ pade ọkunrin naa ni ẹnu-ibode, ni iwaju awọn agbaagba (eyi si ni lati jẹ ni ita gbangba kan, o si wo ọkunrin naa ni oju, o si wipe, “Njẹ iwọ lee ra a pada? ”Wayi, lakọkọ o ni lati ra Naomi pada ki o le e ni Rutu; bakana pẹlu ni Kristi lakọkọ ni lati ra ijọ Juu

pada ki O to lee fẹ iyawo ti awọn ẹya Alaikọla. O wọle wa pẹlu Rutu, gẹgẹ bi i alejo lati orilẹ-ede miran, ara Moabu kan, keferi kan. Ohun ti awa jẹ ni iyẹn, ẹya Alaikọla ni awa, awọn keferi. Ẹ si ranti pe, o ni lati gba Naomi. Nigba ti o ra Naomi, o jogun ohun gbogbo ti Naomi ni.

77 Ranti, nigba ti Kristi de, Oun ko fi igba kan ba awọn ijọ ẹya alaikọla sọrọ, O jẹ: O lọ ba awọn Tirẹ. "O tọ awọn Tirẹ wa, awọn Tirẹ ko si gba A." O ma a n lọ ba awọn Tirẹ ni gbogbo igba ni. O ni, "Ẹ maṣe lọ si ọna ti awọn ẹya Alaikọla. "Ẹ maṣe lọ si ọdọ awọn ara Samaria, ṣugbọn kaka bẹẹ ẹ lọ si ọdọ awọn agutan Israẹli ti o sọnu. Ati bi ẹ ṣe n lọ, ẹ waasu ihinrere, ẹ wo awọn alaisan san, ẹ ji awọn oku dide, ẹ le awọn ẹmi eṣu kuro; lọfẹ bi ẹ ṣe gba a, lọfẹ ni ki ẹ fi fun ni." Njẹ bẹẹ ni o ri? O ran wọn ni meji meji. Ẹ lọ lakọkọ.... O ni lati ra ijọ na a pada. Ati nigba ti O ra ijọ naa pada, o wa jogun iyawo ti awọn ẹya Alaikọla. Amin. Iyẹn ni idina-dura naa ninu rẹ. O rii, O gba iyawo nigba ti o ra ijọ naa pada.

78 Wayi, Boasi o ni lati ṣe ijẹwọ ita gbangba.... O wipe, "Njẹ iwọ lee ra a pada bi?"

O wipe, "O ti o."

Nigba naa ni o ni latiṣe ijẹri ita gbangba. O gba bata rẹ danu o si ju u si i, o si wipe, "Bi ọrọ rẹ ṣe ri niyẹn! Jẹ ki gbogbo ile Israẹli mọ wipe mo ti ra Naomi pada, mo si ti gba Rutu pẹlu." Amin. "Mo gba Rutu gẹgẹ bi iyawo mi." Tani ẹni naa? Oluwa ikore ni. Amin. Nibẹ ni o wa. "Mo ra Naomi pada, Rutu si di temi. Rutu yoo si jẹ aya mi."

Kinni wọn yoo sọ? "Njẹ ki o.... dabi Lea ati Rakeli ati awọn iyooku wọn, ki o gbe ẹgbẹgbẹrun dide [o si ti ṣe bẹẹ, bẹẹ gẹlẹ ni) fun Israẹli. Njẹ ki Rutu da bẹẹ." Si wo o, o ṣe ijẹri ti ita gbangba.

79 Kinni Jesu ṣe lati ṣe e? Oun pẹlu ṣe ijẹri ita gbangba. Nigba ti, Satani ko lee ku fun ẹṣẹ nitori pe ẹlẹṣẹ ni o jẹ. Oun ni baba ẹṣẹ. Ṣugbọn Jesu, Alailẹbi naa, Ọlọrun ọrun, Ẹni ti ko ni lati ku! Sọkalẹ O si ṣe ijẹri ita gbangba nipa kiku, a gbe E soke laarin awọn ọrun ati aye. Ẹri ita gbangba kan! A bọ aṣọ kuro ni ara Rẹ a si so O rọ laarin awọn ọrun ati aye pẹlu itiju. O si ku iku ẹṣẹ ati itiju lati ra wa pada. Ijẹri ita gbangba kan. Amin!

Kinni O ṣe. O gba ododo Rẹ danu, O gba ogo Tirẹ danu, o gba danu.... "Mo ni agbara, Emi iba ba Baba mi sọrọ ati lọgan Oun yoo ran awọn ọkẹ-aimọye awọn angẹli." Wọn lee yi ipa ohun kan pada. Angẹli kan iba ti ṣe e; Oun iba ti pe fun ogun lijioni awọn angẹli! Iyẹn iba jẹ ẹgbẹrun lọna ogoji awọn angẹli. Kin ni wọn iba ṣe? O wipe, "Emi lee sọ fun Baba Mi ati lọgan (Iyẹn wara-n-ṣe sa bayi) Oun yoo fi ogun ligioni awọn angẹli ranṣẹ si mi ti wọn yoo wa si ihin lati gba akoso ohun gbogbo nihin." Kinni ẹyọ angẹli kan yoo ṣe? Angẹli kan yoo pa gbogbo aye rẹ ni iṣẹju kan. Saa wo o, Oun ni ẹgbẹlẹgbẹ awọn angẹli ti wọn lee wa. Njẹ o rii? Ṣugbọn O gba iyẹn danu. O gbe eyi ti si ẹgbẹ kan. O gbe gbogbo olá Rẹ, ati ohun gbogbo si ẹgbẹ kan, O si di ẹlẹṣẹ, O si ku fun iwọ ati emi.

80 Wayi ni ipari, a le sọ eyi, ni ipari. O ṣe iyẹn. Lẹyin naa, o gba Rutu, o si gbe e ni iyawo. Oun si bi ọmọkunrin kan, o si pe orukọ rẹ ni Obẹdi. Obẹdi ni baba Jese, Jese si ni baba Dafidi, ẹni ti o jẹ baba Kristi (Amin), baba Oluwa wa, Oluwa Jesu. Njẹ iwọ ko ri i bayi? Eyi wa nipa ododo naa, nipa ipinnu san an naa ti a ṣe!

O wa di Ibatan Olurapada wa. Ọlọrun di ibatan si wa, fun Un lati sọkalẹ ti a si ṣe E bii tiwa, eniyan ẹlẹran ara kan, ebi pa A, oungbẹ gbẹ Ẹ. "Oungbẹ n gbẹ Mi, ẹ fun Mi ni omi mu," wọn si da ọti kikan ati oro-n-ro si I ni ẹnu.

Oungbẹ gbẹ Ẹ bi o ṣe ma a n gbẹ awa pẹlu. O mọ bi a ṣe n ṣẹ ara ẹni. O saisan bi awa pẹlu ṣe ma a n saisan. O wipe, "Njẹ wọn ko ni pa owe aitjọ naa fun mi pe, Onișegun wo ara rẹ san?" Ṣugbọn agbara Rẹ nla ko wa fun ara Rẹ. O ni agbara lati ṣe e, ṣugbọn Oun ko le lo agbara naa fun ara Rẹ.

81 Ẹnikan sọ fun mi ni ijeloo, pe, "Arakunrin Branham, ki ohunkohun to ṣẹlẹ, iwọ yoo sọ ohun ti yoo ṣẹlẹ si ọ."

Mo dahun pe, "Ẹbun naa ko wa fun anfani mi, emi ko lee lo fun ara mi." O wa fun ẹyin eniyan yii. Ẹyin ni ẹ n jẹ anfani rẹ, emi kọ. Iranṣẹ Ọlọrun fun ẹyin ara ilu ni emi jẹ.

Iranṣẹ ara ilu ni oniwaasu jẹ. O saa n gbe ara rẹ kalẹ sibẹ bẹẹ ni, gẹgẹ bi ododo lili ti inu oko: oyin n fo wa, yoo si mu ipa tirẹ, agbọn yoo fo wa yoo si la oyin tirẹ, awọn ti wọn n rekọja lọ yoo wa n wọn yoo wa, wọn yo si gba ipin tiwọn naa ati ohun gbogbo bẹẹ. O n ṣe laalaa lọsan ati loru lati lee pa ẹwa rẹ mọ. Oniwaasu Ọrọ ihinrere n ṣe bakan naa. O n rin ni ipa ti Ọlọrun, o n di otitọ ti ẹri otitọ rẹ mu ki aye lee jẹ anfani lara rẹ, o rii. Ọgbẹni Olusọ-agutan Lili. Ẹni rere kan ni o jẹ. Jesu wipe, "Ẹ gba ọrọ rẹ wo. Solomoni paapaa ko dabi tirẹ." Bẹẹ ni. Dokita Lili, mo ro wipe gbogbo yin mọ ọn, o rii.

82 "Gba ọrọ ododo Lili ti inu oko wo, bi wọn ṣe n ṣe laalaa, ti wọn ko si.... Mo wipe Solomoni paapaa ninu

gbogbo ogo rẹ....” Ododo Lili ni lati ṣe akitiyan lọsan ati lori lati le ni ẹwa rẹ ati lati le pa aṣọ rẹ mọ, lati le pa oorun didun ati awọn nnkan rẹ bẹẹ lee ma a tẹsiwaju. O saa n ṣi ara rẹ silẹ ni ki awọn iyooku bi wọn ti n re kọja lọ ki wọn lee gba ohun tiwọn lọdọ rẹ. Oyin naa ati awọn kokoro ti n fo gbogbo ati ohun gbogbo bẹẹ n rekọja lọ, wọn iba dara tabi buru, wọn n jẹ anfaani rẹ.

Bi ti iranṣẹ Kristi, ani Kristẹni ti o jẹ iranṣẹ ṣe ri niyẹn. O n ṣi ara rẹ silẹ, o n wipe, “Ẹyin eniyan aye, ẹ wa jẹ anfaani mi.” Ko fa ohunkohun sẹyin fun ara rẹ, ohun gbogbo jẹ fun anfaani awọn ẹlomiran. Ohun ti Kristi jẹ niyẹn nigba ti O di ibatan fun wa! O di eniyan ki aye le jẹ alabapin ninu Ododo Rẹ, o rii, ki a le ṣe wọn ni awọn ọmọ Ọlọrun.

83 Wayi, kinni wọn ṣe? Wọn ṣe igbeyawo, ati nipaṣẹ iyẹn ni ohun nla yi waye.

Nigba naa ni a fun Rutu ni èrè, nipa nini Kristi.... tabi nipa nini Boasi gẹgẹ bi ọkọ rẹ. A si n fun ijọ ni ere nipa.... nigba ti bibọ Oluwa yoo de ni owurọ ọjọ ti o mọlẹ ti ko si ikuuku kankan mọ. Awa n simi, a si n duro de owurọ naa bayi. Yoo de. Wayi.... Erẹdi rẹ, awọn ẹni irapada ni.

84 Wayi, ẹ jẹ ki n mu ọrọ kan sii wa ki a to bẹrẹ sii gba adura fun awọn alaisan; ẹyọ ọrọ kan sii. Ni owurọ yii, mo wadi nipa itumọ ọrọ ti irapada naa. Ẹ jọwọ ẹ gba mi laaye, ẹyin ara Arminiani mi, ṣugbọn mo sa a ni lati sọ eleyi nihin, kii ṣe lati pa ẹnikẹni lara, ṣugbọn lati lee jẹ ki ẹ ronu. Ẹyin ẹ ṣe ayẹwo ohun ti ọrọ irapada yii tumọ si. Ninu ọrọ Giriki, Irapada ni tootọ ni i ṣe pẹlu mimu ẹru kan jade lati ọja kan wa. Emi ko lee pe ọrọ Giriki yii ni lẹta kọọkan bayi, ṣugbọn ohun ti o tumọ si ni “Mimu ẹru kan kuro ni ọja” - lati ra pada.

Iyẹn ni pe ki ọkunrin kan ṣe ohun ti ko dara, nitori naa, ki ẹni ti o ni ẹru naa wa ta a si ọja ẹru, ni tootọ o jẹ ki a ta a si inu iku. Ọkunrin naa si wa ni ọja naa, ẹru si ni. Ṣugbọn ọkunrin miran wa wa, iyẹn ọkunrin ti o kun oju oṣuwọn, ti o si ni agbara lati ṣe e, ti o si wa ri ọkunrin yii (ti ọkunrin na si wa ri oore-ọfẹ gba ni iwaju rẹ), ti o si ra a pada kuro ni oko ẹru naa. Eyi yoo mu ẹru naa kuro ninu ọja ẹru yii, yoo si mu un wa fun ara rẹ. Wa kiyesi bayi pe lọgan ti o ti ra ẹru yii pada lẹẹkan, a ko lee ta ni ọja ẹru naa mọ. Amin. A ko lee ta ẹru yii mọ laelae! O ti gba àmì sara. Ti a ba ni ero ti o dara nipa rẹ nigba kan pe ẹni kan yẹ fun irapada, nigba kan, ko wa si ẹda kan ti o tun lee ta a pada gẹgẹ bi ẹru mọ.

85 Oo, ọpẹ ni fun Ọlọrun! pe nigba ti ọkunrin kan lẹẹkan ba ti wa si ọdọ Kristi ti a si ti ra a pada kuro ni oko ẹru nipa ẹjẹ iyebiye naa, eṣu ko lee sọ ọ di ẹru mọ laelae. Aabo rẹ ti daju ninu ẹjẹ Jesu Kristi ti di ọjọ irapada rẹ. Gẹgẹbi ẹru (ṣe ayẹwo eleyi ni Iwe Ekisodu ko si wadi rẹ bi eyi ko ba jẹ ofin ti Lefitiku. Ohun ti mo ni lọkan ni Lẹfitiku, wadi boya ohun ti ofin sọ kọ niyẹn), ẹru kan ti a ti ra pada nigba kan ri, a ko lee taa pada mọ gẹgẹ bi ẹru. Bẹẹ ni o ri. Oo, inu mi dun jọjọ. Inu mi dun pupọ lati mọ wipe Ibatan Oludande wa, pe Ọlọrun ọrun naa, Ẹni ti i ṣe Ẹ̀mí Ọlọrun, sọkalẹ wa si aye a si sọ Ọ di eniyan (A da A bi i ti emi, a da A bi i ti iwọ) Oun si gbe irisi eniyan ẹlẹṣẹ wọ bi o tilẹ jẹ wipe Oun ko mọ ẹṣẹ rara, pe ki ẹṣẹ wa lee simi le E lori, O si di ibatan wa, O ṣe ijẹri ita gbangba ti kiku Rẹ nipa eyi ti O fi san ẹkunrẹrẹ owo itanran naa.

Ẹmi Ọlọrun si jẹri pada. A fa tẹmpili naa ya.... aṣọ ikele naa ya lati oke de isalẹ. Kii ṣe lati isalẹ de oke, ṣugbọn lati oke de isalẹ, ti o fi han wa pe, Ọlọrun funra ara Rẹ ni o fa a ya lati oke; O ya a lati oke de isalẹ, O si la ọna naa. A si da oju okuta irubọ naa de ilẹ, imọna-mọna si la gaara kọja inu okunkun na, oju ọrun ti o binu, oorun si wọ ni aarin ọsan gangan, awọn oṣupa taku wọn kọ lati tan imọlẹ wọn, ohun gbogbo ni o siṣe Ijẹri tirẹ! A ti ra wa pada. Alleluya!

86 Ẹ jẹ ki a gbadura. [Ọkunrin kan ninu ijọ jẹ iṣẹ kan. “Bẹẹni, ẹyin ọmọ Mi, Oluwa n sọ fun yin ni owurọ yii, ẹ fasunmọ Oluwa, bẹẹ ni, ani gẹgẹ bii Rutu ṣe rọ mọ Naomi, ti a si mu un wa si ilẹ-ileri, bẹẹni, bẹẹ pẹlu ni ẹyin naa, bi ẹyin ba rọ mọ Ọrọ Oluwa, a o mu yin wa sinu awọn ileri Oluwa naa. Bẹẹni, a o mu yin wa sinu isimi Mi, ni Oluwa wi. Ati gẹgẹ bi ẹkọ opomulero ijọ ti i maa n rọ bi iri ni wakati yii, bẹẹni, Ọrọ Mi n jade lọ nipa awọn iranṣẹ Mi. Bẹẹni, yoo si yi gbogbo aye yii ka. Ṣugbọn ayaafi bi a ba kun un yin pẹlu Ẹmi Mimọ, ẹyin ko ni mọ ohùn Oluwa. Nitori naa Oluwa n sọ fun yin pe ẹ yara yin kuro ninu aiṣedeede, bẹẹni, ẹ fọ igbesi-aye yin mọ, ẹ fi gbogbo awọn nnkan wọọni ti o jẹ ti aye silẹ, bẹẹ ni, awọn nnkan ti wọn jẹ ti ara, ti wọn ko jẹ ti ifẹ inu si Oluwa. Nitori Oluwa n sọ fun un yin ni wakati yii, pe ayaafi tị eyin ba ronupiwada, bẹẹni, ayaafi tị eyin ba yi pada si Oluwa pẹlu gbogbo aya yin, ki ẹ si ṣetan lati fi awọn ti o ku lẹyin naa silẹ, Oluwa ki yoo gbọ yin nigba ti O ba de. Nitori Oluwa n pada bọ gẹgẹ bi i ọkọ iyawo fun aya Rẹ. Ati gẹgẹ bii iyawo ṣe ma n gbaradi, ti o si ma a n pese ara rẹ silẹ fun bibọ ti ọkọ iyawo naa, bẹẹ gẹlẹ ni awọn ọmọ Mi ni lati mura ara wọn silẹ ani ni wakati yii, ki wọn lee wa ni imurasilẹ ni akoko bibọ Mi, ni Oluwa wi. Nitori naa, ẹ ma a fi oju sọna, ki ẹ si maa gbadura, ni Oluwa wi. Ẹ tẹtisi Ohun Mi ti o n jade wa, nitori Ọrọ Mi ki yoo pada tọ Mi wa lofo, ṣugbọn yoo muṣẹ, awọn nnkan wọọni ti mo ti yantẹlẹ, ni Oluwa wi, ti yoo si wa si imuṣẹ ni opin ọjọ yii. Nitori naa, ẹ tẹtisilẹ, ẹ tẹtisilẹ, ẹ yipa kuro ninu ọgbọn tiyin, ẹ kuro ninu ẹkọ igbagbọ yin, bẹẹ ni, ẹ yipada kuro ninu awọn ohun naa ti wọn ti dari yin sinu igbekun, ki ẹ si yi ẹsẹ yin pada sinu Ọrọ Ọlọrun, a o si sọ yin di ominira. Bẹẹni, Aanu Mi yoo wa ni ori yin, ni Oluwa wi.”]

Pẹlu ori yin ni titẹba, wayi, ni iṣẹju kan.... Ọrọ asọtẹlẹ ni o jade yẹn, ti o n pe si ijọ lẹyin ti iwaasu ti jade.

Bayi, bi awọn kan ba wa nihin ti wọn ko mọ Oluwa, ti igbesi aye yin ko tọ, a pe yin bayi lati dide duro nihin, ni iwaju akojọpọ yii - ni iwaju Ọlọrun - lati tẹwọ gba A gẹgẹ bi Olugbala yin. Omi ti wa ninu adagun odo naa fun iribọmi. Ẹnikan wa ti o ti n duro lati bẹrẹ isin iribọmi ni kiakia bayi.

87 Nigba ti ori wa wa ni titẹba, a o lo akoko yii lati bẹrẹ si i kọrin, "Emi yoo La a Ja." Pẹlu ori yin ni titẹba bayi.

Emi yoo la a ja, bẹẹni, emi yoo laa ja,
Emi yoo san iye-owo naa, ohun yoowu
Ti awọn iyoku n ṣe.
Emi yoo mu ọna nii pọn pẹlu awọn
Eniyan Oluwa diẹ naa ti a kẹgan,
Emi ti bẹrẹ pẹlu Jesu, emi yoo si la a ja.

Emi yoo la a ja, bẹẹni, emi yoo laa ja
Emi yoo.... (Njẹ ọrọ yii ti ọkan rẹ wa ni tootọ bayi?

Bi o ba ri bẹẹ, ma a bọ loke nihin ki o wa duro.)
Ohun yoo wu ti awọn miran n ṣe.
Emi yoo mu ọna mi pọn.... (Njẹ iwọ ṣetan lati rọ mọ Ọn bii Naomi ti atijọ?)
Emi ti bẹrẹ pẹlu Jesu, emi yoo si laa ja.

Lati ibujẹ ẹran ni Bẹtilẹhẹmu ni
Alejo kan ti jade
Ni ori ilẹ-aye mo n pongbẹ lati dabi Rẹ
Ninu gbogbo irinajo aye lati aye de inu ogo
Ohun kan ti mo beere fun ni lati dabi Rẹ.

Lati dabi i Jesu.... (Njẹ iwọ n fẹ lati dabi Olurapada naa?) bii Jesu
Ni ori ilẹ-aye, mo n pongbẹ lati dabii Rẹ
Ninu gbogbo irin-ajo aye de inu ogo
Ohun kan ti mo beere fun ni lati dabi Rẹ

Tan imọlẹ Rẹ si mi, Oluwa, tan imọlẹ Rẹ
Jẹ ki Imọlẹ lati ile-imolẹ tan sori mi,
Tan imọlẹ Rẹ si mi Oluwa, tan imọlẹ Rẹ si mi
Jẹ ki Imọlẹ lati inu ile-imọlẹ tan si mi

Lati da bi i Jesu.... (Njẹ ẹlomiran tun wa, ti yoo fẹ

dabi Rẹ, lẹgbẹ Rẹ?)

Njẹ ẹlomiran kan ko ni wa bayi, ki o si kunlẹ nihin pẹlu ọdọmọ-binrin yii, gẹgẹ bi o ti kunlẹ? Ti o n mu ọna rẹ pọn, gẹgẹ bi i Rutu ti atijọ, ti ọna rẹ pọn ni owurọ yii

..... lati dabi Rẹ

Ninu gbogbo irinajo aye yii lọ sinu ogo

Ohun kan ni mo beere fun, o jẹ lati dabi i Rẹ

O jẹ lati dabii Jesu....

Ki ẹlomiran ma a bọ loke bayi, maa rin bọ nihin. Ki o si kunlẹ, gẹgẹ bi i ọdọmọ-binrin yii ti ṣe nihin. Njẹ iwọ ti bẹrẹ? Njẹ iwọ yoo fi ọwọ rẹ si inu ọwọ Rẹ?

. . . mo n pongbẹ lati dabi Rẹ

Ninu gbogbo irinajo aye

Lati aye de inu ogo

Ohun kan ni mo beere fun,

O jẹ lati dabi Rẹ.

88 Baba wa ọrun, nigba ti ijọ n kọ orin yii sinu, "Lati dabii Jesu;" obinrin yii, ni owurọ yii ti jade si ta bii Rutu. Ina Belle, n wa bi i Rutu ti atijọ, ko si oye ti owo itanran naa iba lee jẹ, o ti wa bayi lati san an, ohunkohun ti

iba a jẹ.... bi o ti yẹ ki a fi obinrin yi rẹrin, tabi ki a fi ṣe yẹyẹ to, o ti duro ni ipo naa bayi, o duro nihin o n jẹwọ awọn ẹṣẹ rẹ. O kunlẹ, o sami si ibi naa ti Oluwa ikore nla naa ti fi ẹgbẹ lelẹ si, ni ibi agbelebu nibẹ lati gba Ẹmi Rẹ. Oore-ọfẹ Rẹ ba obinrin yii sọrọ gẹgẹ bi Ọrọ Rẹ ṣe jade tọ ọ wa - bi Naomi atijọ, o n dari rẹ. O si kọlu eyi ti o tọ naa ni ibi ti o tọ naa. Ati bayi o n wa lati duro ni ipo onigbagbọ kan, o kunlẹ ni ibi agbelebu naa, nibẹ nibi ti o ti n jẹwọ awọn ẹṣẹ rẹ, ti o n pati si ẹgbẹ kan gbogbo awọn ohun ti atijọ, ti o wa n di ẹda titun bayi ninu Jesu Kristi.

89 A gba adura, Baba, lowurọ yii, wipe gbogbo ajeji ọkan ninu gbọngan yi, gbogbo obinrin kọọkan, gbogbo ọkunrin kọọkan, gbogbo ọmọdekunrin tabi ọmọdebinrin ti ko mọ Jesu, maṣe jẹ ki Ọrọ yi lọ lofo bẹẹ, Ọlọrun. A wa ko mọ akoko ti a ma wa si ibi idajọ Rẹ. O le jẹ loni ni ọpọlọpọ wa ma ni lati wa. O le jẹ ki a to o de ile, jamba ọkọ kan le ṣẹlẹ, boya aarun ọkan le mu wa. Awa ko mọ. Aaa Ọlọrun, jẹ ki a pese ara wa silẹ ni wakati yii, nigba ti Ẹmi Rẹ wa nibi, nigba ti a ni ẹri wipe Jesu wa niyin; nigba ti Ọlọrun ọrun, ninu anu Rẹ ti ko lopin, wa niyin lati mu wa wọle.

Fun wa ninu oore ọfẹ Rẹ, Ọlọrun, ran ọpọlọpọ si ori pẹpẹ lowurọ yii lati gba Jesu Kristi gẹgẹ bi Olugbala wọn gẹgẹ bi obinrin yi ti n ṣe bayi, ki o ri bẹ, Ọlọrun. Wa ṣe aanu fun un ni, ni mimọ wipe awọn eniyan rẹ.... arakunrin rẹ joko pẹlu mi ni ori pẹpẹ, arabinrin rẹ Wood joko ni ita ni bẹ yẹn, mama ati baba rẹ joko ni hin. Oluwa Ọlọrun mo gbadura fun aanu. Ko ri bẹ Oluwa. O mọ ohun ti mo ni ni ọkan mi. Mo beere pe ki ẹjẹ yin ti Ẹ ta silẹ ninu aanu ki o sọkalẹ ni wakati yii. Bẹẹ ni ki o ri, Oluwa, ki o ri bẹ nigba ti a n duro de awọn ìyókù, njẹ ki awọn ìyókù naa wa, Baba, ki wọn si ba Ọlọrun laja nipasẹ Kristi.

90 Bi a ṣe n duro bayi, ti o n ṣe wa ni kayeefi, awa yo kọ orin lẹẹkan sii.

Tan imọlẹ Rẹ si mi, Oluwa, tan an si mi
Jẹ ki imọlẹ lati ile Imọlẹ tan an si mi

O da bẹẹ:

Tan an.... (ṣe ẹlomiran si n bọ wa?)

Tan an si mi
Jẹ ki imọlẹ lati ile imolẹ ki o
Tan si mi
Tan an simi, Oluwa tan an si mi,
Jẹ ki imọlẹ lati ile imọlẹ
Ki o tan simi.

Bawo ni yoo ṣe ṣe mi?

Lati dabi Jesu, lati dabi Jesu,
Ninu aye mo fẹ ki n dabi Rẹ (Jesu);
Ninu gbogbo irin ajo mi lati
Aye de ọrun
Mo ṣa n bere wipe ki n dabi rẹ.

91 Ọlọrun baba, eyi ni ijẹri ọtitọ wa Oluwa, awa fẹ dabi Rẹ; ki a jẹ oniwatutu, oniwa irẹlẹ, ti o ni onirẹlẹ, ẹni ti o dun, ti o ma n dariji awọn ti wọn ba ṣe lodi ti wọn si ṣe ohun ti o kuna si i. Awa fẹ jẹ bẹ naa. Awa dupẹ lọwọ Rẹ fun obinrin yii ti o wa ni owurọ yii. Kinni a mọ wipe aye yii yoo parada da bayi, lẹhin igba diẹ. Boya ninu gbogbo ikuna rẹ ati gbogbo awọn nnkan ninu aye (gẹgẹbi gbogbo wa ti ṣe) ni riri wipe gbogbo wọn ti bọ si abẹ ikun omi ni owurọ yii, mo gbadura, Ọlọrun, wipe ki obinrin yi gbe igbesi aye ti a ya sọtọ ti yoo mu awọn alabarin rẹ wa si iriri yii. Ki o ma ṣe duro ni ihin yi, ṣugbọn ki o lọ si ilẹ ileri, ki o sami sibẹ ki o si sun sibẹ ki o gba Ẹmi-Mimọ nibẹ. Jẹ ki o ri bẹ Oluwa.

Bi awọn miran ba wa nibi Baba ti o yẹ ki n wọn wa ti wọn ko si wa, ki Ẹmi Rẹ maṣe fi wọn silẹ. Ki wọn ki o ma ṣe ni isimi; ni ọsan tabi ni oru, titi ti wọn yoo fi wa pẹlu lati ṣe ipinnu yi i. Ki I ṣe lati kanra mọ wọn, Oluwa, ṣugbọn, Ọlọrun, ni mimọ ohun ti wọn n pàdánu - lati mọ ohun ti yoo ṣẹlẹ ni ọjọ yẹn lati gbọ Jesu ti yoo wipe, “Ẹ kuro ni ọdọ mi, éyin onìṣẹ ẹ̀ṣẹ̀. Ni owurọ ọjọ na a ni Opopona Eight ati Penn, mo pe ọ, iwọ ko si wa.” Oo Ọlọrun iru wakati ti o buru jai wo ni yoo jẹ fun wọn nigba ti a ba wọn wa lori sikẹli ti a ko si kun oju oṣuwon. Baba, jọwọ maṣe jẹ ki iru eleyi ṣẹlẹ si ẹnikẹni niwaju Rẹ. Jẹ ki a gba gbogbo wọn laa. Ni orukọ Jesu ni a gba adura. Amin.

92 A fẹ dupẹ lọwọ Oluwa ni owurọ yii fun oore ati inu rere Rẹ si wa. Mo si dupẹ lọwọ gbogbo yin fun suuru yin ni diduro pẹlu mi fun igba pipẹ, naa. Arabinrin Ina Belle Emi.... Arabinrin Wood, aburo yin ati Arakunrin Charlie niyẹn. O jẹ ohun ti wọn ti n gbadura fun, ti awa pẹlu ti gba adura fun, fun igba pipẹ. Arabinrin Ina Belle, njẹ iwọ yoo dide duro fun akoko kukuru? Oun ni.... Aburo ọkọ Arabinrin Wood, ẹni ti o jẹ alabojuto ijọ wa nihin, o gba Jesu gẹgẹ bi Olugbala rẹ ni owurọ yii. Ọpọlọpọ adura ni a ti gba fun un.... Ki Ọlọrun ki o bukun ọ, Arabinrin Ina Belle. Mo ro wipe mo pe orukọ rẹ daradara bayi. ṣe bẹẹ ni? Ki Ọlọrun ki o bukun ọ titi

lae, arabinrin ọwọn. Bi a ko ba si ti i ṣe iribọmi fun ọ ni orukọ Oluwa wa Jesu Kristi, mo rọ ọ lati ṣe bẹẹ ki o si gba Ẹmi Mimọ naa.

Njẹ ki Ọlọrun ki o wa pẹlu rẹ titi lae, ki O si bukun ọkọ rẹ ọwọn nibẹ. Mo pade rẹ ni ọjọ diẹ sẹyin. Be emi ko ba ṣe aṣiṣe, Stanley ni orukọ rẹ. Ṣe bẹẹ ni? Ki Ọlọrun ki o bukun ọ Stanley. Ẹbi alayọ ni, ṣugbọn mọ gbagbọ wipe, ayọ yoo tun kun ẹbi naa bayi ju bi o ti lee kun tẹlẹ lọ. Ki Ọlọrun ki o wa pẹlu yin titi lae, ki o si fun yin ni oore-ọfẹ ati aanu Rẹ ni gbogbo ọjọ aye yin. Ẹ si ma tẹle Oluwa siwaju ati siwaju sii. Ina Belle, dabi Rutu bayi, rọ mọ on taara. Saa ma a tẹsiwaju ni. Ni igba miran ọna naa lee nira, ọna naa si lee ṣóòkún diẹ, ṣugbọn ranti: Saa wo isalẹ, lẹyin naa wo oke ni oju ọrun. Iwọ yoo ri oju bata ẹsẹ ti o kun fun ẹjẹ, iyẹn ni ki o tẹle lọ si oke nibẹ: Oluwa yoo dari ni oju ọna naa.

93 Wayi, ọsan ti de-aago mejila ọsan ti lu. Njẹ ẹ si n fẹ ki a pe fun ila adura? Billy, nibo ni.... Njẹ o pin kaadi adura? Emi ko.... mo gbagbọ wipe o sọ fun mi pe oun pin kaadi adura.... Kin ni? Ẹ jẹ ki ẹnikan sọ fun un mi ohun ti lẹta ati nọmba naa jẹ? Ṣe B? B - ṣe ookan de ọgọrun?.... aadọta si ọgọrun. O ti daa. B nọmba kinni.

Wayi, ero pọ, nitori naa, awa ko lee.... a o mu ki gbogbo wọn duro, a o si mu wọn la ila adura kọja, ti a o ma a gbadura fun wọn.

94 Wayi, awọn melo ni wọn ko i ti i ri ọkan ninu awọn gbigba adura fun awọn alaisan ri? Ẹ gbe ọwọ yin soke, ẹ ko i ti i wa sinu ọkan ninu awọn ipade adura mi fun awọn alaisan ri. Oo, kaasa, ẹ pọ pupọ gan an ni.

Wayi, a saa le gba adura fun awọn eniyan, tabi ki a ṣe imọ-ọkan-yatọ, tabi ki a ma tilẹ to awọn eniyan fun adura rara, ki a saa ma a pe wọn si ita laarin ijọ. Ko ṣe nnkan kan, Ẹmi Mimọ wa nihin. Bẹẹ ni. Ṣugbọn ẹ yẹ ki a to fun adura. Nomba kinni. Tani o ni nọmba kinni? Kaadi adura a B nọmba.... 50. Mo tọrọ aforiji. Ko si ẹni ti o ni nọmba kin-in-ni. Ko lee si. O ti daa. Kaadi adura aadọta, taani o ni in? Ma a bọ loke nihin, alagba. Kaadi adura 51, 52, kaadi adura 52, O ti dara. Kaadi 53, 53. O ti dara 54. Ẹ ma a bọ si iha ihin, taara loke nihin. Bi o ba wa ni ọwọ ẹyin lọhun, ma a bọ si ihin. Kaadi 51, 52, 53. O ti dara, Kaadi 54. Tani o ni kaadi 55. Ọmọbinrin ti o wa niha ihin. Kaadi adura 56. Dide duro ni ẹgbẹ ogiri lọhun naa, bi o ba fẹ. Kaadi 57, 58, 59, 60, 61, 62, 63, 64, 65. Busty, yi pada si ọna aarin ijọ taara nibẹ, arakunrin, nibẹ taara lọhun, o ti dara. Yi si ipa ihin.

Awọn melo ni wọn ko ni kaadi adura ti wọn si fẹ ki Oluwa ki o wo wọn san, ẹ gbe ọwọ yin soke. O ti dara. Gbogbo ohun ti ẹ ni lati ṣe niyẹn. Ẹ saa gba eyi gbọ bayi. Ẹ saa gbagbọ. O ti dara. Kaadi adura 56. Njẹ mo ni in? Kaadi 57, 58, 59, 60. Ẹ jẹ ki wọn dide duro. Kaadi 61, -2, -3, -4, -5, ẹ jẹ ki wọn dide duro. Kaadi 66, 67, 68, 69, 70, ẹ jẹ ki wọn dide. Emi ko fẹ ki gbogbo wọn maa da giiri ni igba kan naa, idi niyẹn ti mo fi n pe awọn nọmba naa. De kaadi 70. Kaadi adura 70 si 80 ẹ dide duro, ẹ ma a bọ nihin, ni ẹgbẹ yii, awọn kaadi 70 de 80. O ti dara (Arakunrin Branham bẹrẹ si i ka awọn eniyan) O ti dara. Kaadi 80 de 90, ẹ dide ki ẹ bọ si ẹgbẹ yii. Dọki, ẹ ran wọn lọwọ ni ẹyin lọhun, bi o ba lee ṣe bẹẹ. Awọn pẹlu kaadi 90 si 100, ẹ dide duro si ẹgbẹ yi, ni odi keji nihin.

95 O ti dara, nigba ti wọn n tẹsiwaju ti wọn n to, emi yoo fẹ lati beere nnkan kan lọwọ ijọ. Awọn melo ni alejo ti wọn wa nihin, iyẹn awọn ti wọn ko i ti i wa fun ọkan ninu awọn ipade mi ri? Ọpọlọpọ ni yin o. Awọn melo ni wọn mọ wipe ko si ẹnikan ti o le wo ẹnikeji san? Dokita kan paapaa ko lee ṣe bẹẹ. Dokita ki i ṣe oluwosan. O saa n ran ẹda lọwọ ni. Ọlọrun ni Oluwosan, ẹ rii. Dokita lee to eegun ọwọ, ṣugbọn ko lee wo ọwọ san. Dokita le yọ iyọfun, ṣugbọn ko lee wo ibi ti o ti ge san. Dokita kan le fa ẹyin kan yọ, ṣugbọn ko le da ẹjẹ na duro tabi ki o wo iho eyin naa san. Ọlọrun ni lati ṣe iyẹn.

96 O ti daa, awọn melo ni wọn mọ wipe nigba ti Jesu wa ni aye, ko sọ wipe Oluwosan ni Oun jẹ? Ọkunrin kan ni. O wipe, “Emi kọ ni mo n ṣe iṣẹ naa, ṣugbọn Baba Mi ti O n gbe inu Mi, Oun ni O n ṣe iṣẹ naa.” Njẹ bẹẹ ni? Awọn melo ni wọn mọ pe, nigba ti O wa nihin.... Iru Iṣẹ-Iriju Iwaasu wo ni O ni nigba ti O wa ni ihin? O ṣe ohun ti Baba fi han An lati ṣe. ṣe bẹẹ ni? Awọn melo ni wọn mọ iyẹn? Iwe Johanu Mimọ 5:19. O wipe, “Lootọ lootọ ni mo wi fun un yin: ”Ọmọ naa ko le ṣe ohun kan Funra-Ara-Rẹ, bikọṣe ohunkohun ti o ri Baba ti O n ṣe. [Ṣe bẹẹ ni?], Ohun kan naa ni Ọmọ n ṣe.“

Wayi, nigba naa njẹ Jesu Kristi jẹ ọkan naa ni ana, ati ni oni ati titi laelae? Njẹ iwọ gba eyi gbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ? Ọkan naa ni O jẹ ni ana, ati ni oni, ati titi laelae? Njẹ iwọ gbagbọ wipe Jesu Kristi, ti O jẹ ọkan ni ana, ati ni oni, ati titi lae wipe eyi tumọ si pe ọkan naa ni O jẹ?

O ti dara. Bawo ni O ṣe jẹ ọkan naa? Ọkan naa ni ninu awọn ilana Rẹ kọọkan. Ṣe bẹẹ ni? O jẹ Ọlọrun kan naa, Oluwosan kan naa, Olugbala kan naa, Ọkan ni O jẹ.... iwuwasi Rẹ ko yaatọ gbogbo rẹ jẹ ọkan naa. ṣe bẹẹ ni? Ọkan naa. O dara nigba naa, bi O ba jẹ ọkan naa lana, ti O si jẹ ọkan naa ni oni, Oun yoo ṣe awọn iṣe kan naa. Njẹ bi o ti ri niyẹn? Wayi, awọn melo ni wọn mọ pe otitọ ni ohun ti a sọ yii jẹ.

97 Emi yoo gba akoko kukuru nihin. Mo n ni suuru ni. ni oju mi, ko dabi ẹni pe awọn ti wọn duro ni ori ila yi

to aadọta. [Arakunrin Branham ka awọn ti wọn to] o ti o. Boya awọn miran ninu wọn ti pada sile saaju ipade yii; mo ri awọn eniyan kan lẹyin lọhun ti wọn n lọ. O ti dara, ila kukuru yii. Awọn melo ni wọn yoo saa fẹ ni.... Awọn melo ni wọn jẹ alejo si mi ni ori ila adura na? Ẹ gbe ọwọ yin soke, ti ẹ mọ wipe emi ko mọ ohunkohun nipa yin. Ẹ gbe ọwọ yin soke.

Awọn melo niita ni ibi yi ni wọn jẹ alejo, ti wọn mọ wipe emi ko mọ ohunkohun nipa yin? Ẹ gbe ọwọ yin soke, ti ẹ si mọ wipe aisan n ṣe yin o ti dara. Awọn melo ni wọn yoo fẹ ri ila imọ-ọkan-yatọ naa, ki a lee ṣe kiakia ki a si pari? Wayi, ko jẹ nnkan kan. Mo saa le gbadura fun wọn ki n mu wọn wa la ila adura naa ja; tabi ki gbogbo wọn joko, ẹ saa lọ joko. Ko ṣe nnkan kan, Ẹmi Mimọ yoo mọ ọkan lọna kan naa gẹlẹ. Njẹ ẹyin gba yẹn gbọ?

98 Wayi, bi eyi ba ri bẹẹ, nigba naa ẹ saa dakẹ jẹ fun iṣẹju diẹ. O ti n pẹ wa bayi. Nitori naa, ẹ saa joko jẹ ẹ fun akoko diẹ. Mo fẹ beere nnkan kan lọwọ yin bayi.

(O lee jẹ wipe gbohungbohun ti o kuna ni mo n lo nihin. Ṣe gbohungbohun mejeeji ni o n siṣẹ? Ṣe mejeeji ni o n gbe ohun jade? O ti daa. Eyi pẹlu nkọ?)

O ti dara bayi, ẹ saa fi ara balẹ fun igba diẹ. Emi yoo wo ila yii ki n lee mọ boya mo mọ ẹnikẹni.

Mo mọ ọlọgbẹni yẹn ti o dide duro lọhun yẹn. Mo mọ Earl, mo mọ ọ; Earl Cobbin. [Ẹnikan sọrọ si Arakunrin Branham - Oo bẹẹ ni. Ọkunrin ti o wa loke nihin. Njẹ ọkunrin ti a ṣe ọdẹ pẹlu rẹ loke lọhun ni Colorado niyẹn? Ooo aha, o daju emi ko mọ. Mo gbagbọ pe Earl (sọ fun mi pe ara rẹ ko da pupọ pupọ. Iwọ naa si wa.... Bi o ko ba ni okun lati dide duro pupọ, ẹ jẹ ki.... Ki ẹnikan gbe aga kan fun un lọhun yẹn. Tabi ki ẹnikan dide duro ki o fun un ni aga nibẹ nibi ti o sunmọ ila iwaju, nitori ara ọkunrin naa ko da pupọ pupọ. Akiika, o ti padanu iwọn ọgọrun tabi ju bẹẹ lọ ni ti iwọn rẹ, aisan naa si ti wọ ọ ni ara pupọ. Wayi ẹ jẹ ki o joko nibẹ. Arakunrin ẹ ṣe o.

99 Wayi, ẹ jẹ ki n wo aarin yin. Wayi Earl saa dide duro pẹlu rẹ ni. Wayi ọkunrin ti o duro taara nihin ti o n wo mi, lati agbegbe La Grange, Kentucky. Emi ko mọ orukọ rẹ, ṣugbọn mo mọ ọ. Ati lẹyin naa arakunrin ati arabinrin Kidd nibẹ, mo mọ wọn. Ati ọmọbinrin yii, nihin.... njẹ arabinrin Rook ni? Tabi.... pẹlu obinrin yi nihin mo gbagbọ pe lati Sellersburg, ẹni naa ti oju rẹ fọ. Njẹ bẹẹ ni?

O ti dara, ninu ila yẹn o dabi ẹni pe gbogbo awọn ti mo mọ ko ju bẹẹ lọ. Oo bẹẹ ni ọrẹ mi ọwọn niyi Busty Roggers nihin ni isalẹ ni Milltown. Ati ni isalẹ lori ila lọhun yẹn, mo ro wipe gbogbo awọn iyoku jẹ alejo si mi. Ni iwaju Ọlọrun eyi jẹ bi oye mi ṣe to, gbogbo awọn iyoku jẹ alejo si mi.

100 Wayi, ẹ jẹ ki n wo awọn ti wọn wa ni aarin ijọ. Wayi, ẹyin ti ẹ jẹ alejo si mi, ti ẹ si n ṣe aisan, ẹ gbe ọwọ yin soke - ti ẹ si mọ wipe ẹ ni ẹbẹ adura kan ni ọkan yin. Ẹ gbe ọwọ yin soke, ni ibi yoowu ti ẹ ba wa, ti ẹ mọ wipe, emi.... O ti dara. O daa bẹẹ. Ni apapọ, gẹlẹ bayi kaakiri ni ibi gbogbo.

Wayi, ko ni pa yin lara, ẹ saa ni suuru fun iṣẹju kan tabi meji. Mo fẹ beere ibeere ọwọ kan. Boya ki n bọ si ẹyin eleyi nihin, ki ẹ lee gbọ mi. Mo saa fẹ beere ohun kan lọwọ yin. Wayi, awọn iṣẹ-iwaasu ti mo n waasu rẹ yii, njẹ ẹ gba wọn gbọ pe otitọ ni wọn jẹ? Ẹ ko ni wa si ihin bi ẹ ko ba gba wọn gbọ.

Njẹ Ọlọrun lee ṣe ohun kan bayi lai fun mi ni oye ohun ti mo nṣe? Rara, ko ni ṣe bẹẹ. Dajudaju ko ni ṣe e. Bayi, ti O ba ti ṣe eyi....

101 Wayi, mo n jẹwọ rẹ pe Jesu Kristi ko i ti i yi pada. Iku Rẹ ko yi I pada. O ṣe E logo ni. O si ji dide ni ọjọ kẹta, O si gun oke lọ si ọrun. O si ran Ẹmi Mimọ naa pada wa, Ẹni ti I ṣe Ọlọrun.... njẹ Ẹmi Mimọ ni o wa ni ori Rẹ. Njẹ gbogbo yin ni ẹ gba eyi gbọ. Ati Jesu nigba ti O wa nihin ni ori ilẹ-aye, O wipe, “Awọn iṣẹ ti Emi n ṣe ni ẹyin yoo ṣe pẹlu. Nigba diẹ awọn eniyan aye ki yoo ri mi mọ [Iyẹn awọn ti ilana aye, ẹ mọ, awọn ijọ alaigbagbọ gbogbo saa ni o], wọn ko ni ri mi mọ, sibẹ ẹyin yoo ri mi [ẹyin, iyẹn ijọ naa, onigbagbọ naa]. Nitori Emi [Emi jẹ ọrọ arọpo orukọ ti o duro fun ẹnikan], Emi yoo wa pẹlu yin, ani ninu yin, titi yoo fi de opin aye. [Ati ọrọ Giriki naa nibẹ jẹ opin ohun gbogbo, ti o tumọ si, ”Opin aye“] .... wa pẹlu yin de opin aye. Awọn iṣẹ ti Emi ṣe ni ẹyin yoo ṣe pẹlu.” Njẹ otitọ ni iyẹn?

102 Bayi a ni ijọ Onitẹbọmi, ijọ Eleto, ijọ alatako, ijọ Aguda ati ijọ Paadi, ati pẹlu awọn Juu ti wọn joko siyin ni owurọ yii. A si ni ijọ Ọlọrun, Nasarẹti, Atipo mimọ, Ajẹri Jehofa - gbogbo oniruuru awọn ijọ ẹlẹyamẹya ti wọn wa niyin. Mo wo ayika mo n wo wọn. Ijọ Eleto, ijọ Luta, ijọ a fi ede Ajejiṣẹri Ẹmi Mimọ, oriṣiriṣi awọn ijọ gbogbo. Mo wo yi ka, mo ri awọn ti mo mọ. Gbogbo wọn jẹ alejo ni gbogbo ilu. Ile Ijọ Branham jẹ nkan kekere ni ilu yii. Ṣugbọn wọn jẹ lati gbogbo orilẹ ede.

103 Bayi, Ẹ jẹ ki a mu eyi ki a ronu lori rẹ fun igba diẹ, ronu jinlẹ, ki ẹ si wa ni irẹlẹ, ki ẹ si bẹrẹ ibere yii. Nigbana ti ko ba ku, kini iha rẹ si ọ ati si awọn ti o nṣe aisan yoo jẹ ọkanna loni gẹgẹbi o ti ri lana. Nigbana bawo ni iwa rẹ lana? Eyi: “Mo le, ti iwọ ba gbagbọ,” Ṣe bẹẹni? Ti iwọ ba gbagbọ.“

Ọkunrin naa iwpe, “Oluwa ṣaanu fun wa.” Wipe, “Ẹmi eṣu n fi iya jẹ ọmọ mi ọkunrin.” Mo mu wa si ọdọ awọn ọmọ ẹyin rẹ, wọn si nki gbe wọn pariwo ati gbogbo rẹ.“

O wipe, “Mo lee, ti iwọ ba gbagbọ. Ti iwọ ba gbagbọ, mo lee.”

104 Bayi, kiyesii, bawo ni Jesu ṣe ṣé? Ki ni Jesu jẹ lana? Bawo ni O ṣe sẹ iṣẹ iranṣẹ? Bayi eleyi wa fun awọn alejo bayi, mo n sọrọ si awọn alejo. Ẹ jẹ ki a wo ohun ti o jẹ lana. Yoo gba mi ni iṣẹju mẹta. A o lo awọn ayọka ni awọn ibikan

Nigbati iṣẹ iwaasu rẹ kọọkọ bẹ̀rẹ̀. Ọkunrin kan wa ti orukọ rẹ a ma jẹ Anderu, apẹja, ti a yi ni ọkan pada (o gba Ọlọrun gbọ.); O si lọ lati mu arakunrin rẹ ti a pe orukọ rẹ ni Simọni. Njẹ ẹ ranti eleyi bii? O mu wa si ọdọ Jesu. O jẹ apẹja ti ko mọ iwe, ko tilẹ le fi ami si orukọ ara rẹ. O si wa sọdọ Jesu, Jesu si wo o wipe, “orukọ rẹ ni Simoni Omọ Jona ni iwọ n ṣe.”

Awọn melo lo mọ wipe iwe mimọ ni yẹn? Wọn mọ wipe Mesaya ni yẹn, nitori Ọlọrun ṣe ileri, Mose iṣe ileri, wipe nigbati Mesaya ba de yi o jẹ wolii. Njẹ iyẹn ye wa? Wolii-Mesaya. O si wo, o si wipe, “Orukọ rẹ ni Simoni.” O wipe, “A sọ baba rẹ ni Jona.” O si mọ wipe Mesaya ni yẹn.

105 Obinrin ti o wa ni ibi kanga na a; awọn orilẹ-ede eniyan miran niyẹn. Bayi o jẹ awọn ọmọ Juu ati awọn ara Samaria ni wọn gba A. Awa awọn ẹya Alaikọla, a ko i ti i wọle ni gba yẹn

Awọn ẹgbẹ Rutu. Wayi, obinrin ni ibi kanga, ti o jẹ ara Samaria, o wa lati wa pọn omi. Jesu sọ wipe, “Fun mi ni omi mu.” Kinni O ṣe? O ba sọrọ, gẹgẹ bi emi pẹlu ti le e ba ẹni kan sọrọ lati inu ijọ. O wipe “Fun Mi ni omi lati mu.” Wọn ko i ti I pade ri.

Obinrin naa si wipe, “Kinni o de, ki i ṣe asa wa, a ni iyapa nihin.” Gẹgẹbi a ṣe ma n ni ni Guusu Amerika, pẹlu awọn ọrẹ wa alawọ dudu ati ohun gbogbo bẹẹ. (Ṣugbọn wọn ko ni mọ; a dupẹ lọwọ Ọlọrun fun iyẹn.) Obinrin naa wipe, “a ni ipinya nibi; ki iṣe asa fun Ọ, iwọ ara Juu.” Jesu jẹ ara Juu. Obinrin yi jẹ ara Samaria. O wipe ki iṣe asa fun Ọ lati beere iru nnkan bẹẹ lọwọ mi emi obinrin ara Samaria, tabi iru eyi.“

Jesu wipe, “Ṣugbọn ọmọbinrin, ti o ba mọ iru ẹni ti iwọ n ba sọrọ, iwọ i ba ti beere omi ni ọwọ mi.”

Eleyi jẹ ki obinrin arẹwa naa duro; o si woke, o wipe, “Kinla, Iwọ ko ni ohun ti Iwọ yoo fi fa omi naa, kanga yii si jin pupọ.”

Jesu wipe, “omi ti emi yoo fun ọ jẹ, omi aiyeraye.”

Ni igbẹyin gbẹyin, o mọ iṣoro rẹ. Eyin melo (ẹyin alejo) ni o mọ iṣoro obinrin yii? O ti ni ọkọ marun. Kinni Jesu sọ fun obinrin naa? Jesu wipe “Lọ, pe ọkọ rẹ wa si ihin.”

Obinrin naa si wo Jesu “O ni emi ko ni ọkọ.”

Jesu wipe, “O sọ otitọ ni o sọ: nitori o ti ni ọkọ marun, ati wipe eleyi ti o ngbe pẹlu rẹ bayi ki i ṣe ọkọ rẹ.”

106 Obinrin na si wipe, “Alagba, mo ni imọlara wipe wolii ni Ọ. Awa mọ wipe nigba ti Mesaya ba de, iyẹn ni Jesu: Nigba ti Mesaya baa de, Oun yoo sọ fun wa awọn nnkan wọnyi. Nitori ti a mọ wipe yoo jẹ Wolii. A wa mọ wipe nigbati Mesaya ba de, yoo ṣe eyi, ṣugbọn tani iwọ?

Jesu wipe, “E mi ni.”

Lori iyẹn, obinrin naa sa lọ si ìlú o wipe, “Ẹ wa, wo ọkunrin kan ti o sọ ohun gbogbo ti mo ti ṣe fun mi: njẹ eyi ki ṣe Mesaya naa?”

Bi iyẹn ba jẹ ami Mesaya lana, ati wipe o jẹ ọkan naa loni, ọkan na lo jẹ loni. Bayi, njẹ ẹyin alejo gba eleyi gbọ? Eleyi ki ṣe fun yin ni ori ila ni ibi yii.

107 Bayi si awọn ti o wa ni ita lọhun, Iwe Mimọ kan wa, ki ẹ le ri nnkan kan lati le duro le. Awọn melo ni wọn gbagbọ wipe Oun ni Olori Alufa bayi, ti a le fi ọwọ ailera wa kan? Gbogbo yin....

[A ko gbọ ohun mọ lori ẹrọ ti a fi n gba ohun silẹ.] Iṣoro rẹ niyẹn. O jẹ ki arun ẹya ara ti ibalopọ kan. Bi o ṣe ri niyẹn. O ma a n dide ni oru ati bẹẹ bẹẹ lọ. O wa lati Ohio. O si jẹ ọmọ ijọ arakunrin Sullivan ti o duro nihin yii, tabi o ma a n lọ si ijọ naa. O wa pẹlu awọn ọmọde kan, ohun ti o ṣe ni yẹn. Otitọ ni yẹn. O dara bẹẹ, ni wakati yi o ni imọlara ti o yatọ bayi. O ti fi Ọ silẹ. Bayi o le lọ si ile, igbagbọ rẹ ti mu ọ lara da. Ki Oluwa ki o bukun rẹ (Erọ ti a fi n gba ohun silẹ danu duro.]

108 Ṣugbọn emi, ni mimọ ohun kohun nipa rẹ, Ọlọrun ọrun mọ wipe emi ko mọ ohunkohun nipa rẹ. Emi ko mọ ohun ti o kuna nipa rẹ. Ko si ọna ti mo fi le mọ ohun ti o kuna pẹlu u rẹ. Iwọ sa jẹ ọkunrin kan ti o duro si

ihin ni. O si ni kaadi Adura daani.... O si ni nọmba kan lara rẹ, o saa.... Ọmọdekunrin naa fun ọ ni kaadi, a si pe ọ wa si iwaju nihin si ori ila adura.

Wayi, ẹ wo bi awọn iran na a ṣe n si. Ẹ rii, ni ẹẹkan pere naa. O tun le ju iwaasu lọ, eyi mu mi ni imọlara ju igba kan lọ, ju gbogbo igba ti mo ti fi waasu lọ ni owurọ yii. Ohun kan n jade, ẹ rii. Ohun kan n jade.

Iwọ ọkunrin yi, ni tootọ iwọ ko wa si ihin nitori ara rẹ. O wa nitori ẹlomiran kan, iyẹn si jẹ ọmọ kekere kan. Ọmọ kekere naa ko si ni ihin, o wa ni ilẹ kan ti o tẹju, Kansa ni. Ọmọ kekere naa ni arun kan, bii warapa ni. Ohun ti o jẹ ni wárápá. Okunkun wa ni ori ọmọ na! Iwọ ni ibaṣepọ pẹlu awọn kan, tabi iwọ jẹ.... awọn Strickers. Njẹ awọn arabinrin kan kọ ni ẹ jọ fẹ tabi ohun kan ti o jọ bẹẹ? Bẹẹ ni. Njẹ iwọ gbagbọ? Ọmọ naa ko ni ni arun naa mọ. Iyẹn bi iwọ ba gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ. Gẹgẹ bi o ṣe gbagbọ, bẹẹ ni yoo ri fun ọmọkunrin kekere naa. [Aye kan sofo lori ẹrọ ti a n gba ohun silẹ]

109 O n gbadura fun aburo baba tabi iya rẹ ti o jẹ obinrin naa, o ni aarun jẹjẹrẹ nibẹ yẹn.

Ṣe o gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ nibẹ yẹn? Emi ko mọ ọ ri i. Emi ko ti i ri ọ ri ni aye mi. Ṣugbọn nigbati o gbọ ti mo sọ nnkan ti ọkunrin naa n ronu nipa rẹ, ibatan kan, iyẹn tọ ọ wa. Bayi ṣe o gbagbọ pelu gbogbo ọkan rẹ?

Bayi kinni o fi ọwọ kan? Mo fẹ ki awọn kan sọ fun mi ohun ti obinrin yẹn fi ọwọ́ kan [Aaye ti o sofo wa lori ẹrọ ti o n gba ohun silẹ]

Njẹ o ti di meji bayi, tabi melo ni? O ti di mẹta? Meji.... Meji? O dara

O dara. Ojiji iku ti wa lori ọmọbinrin naa. Ojiji dudu kan ti wa ni ori rẹ, eyi ti o fi han wipe o ni jẹjẹrẹ. Otitọ ni eyi. Dokita sọ fun ọ wipe, jẹjẹrẹ ti o wa ninu ẹya ara kekere ti o n mu awọn ẹjẹ adaabo bo ara jade. Ti eyi ti mo sọ yi ba jẹ otitọ, naa ọwọ rẹ soke. O wa lati ibi ti o jin si ihin; Iowa. Njẹ o gbagbọ? Boya o ni ọmọkunrin kan tabi.... O jẹ ọmọ-ọmọ rẹ, o ni arun oju kan ti o n yọ oju rẹ lẹnu, o si n gba adura fun un. Njẹ o gbagbọ wipe Ọlọrun le sọ ẹni ti o jẹ fun mi? Arabinrin Mickee. Nibayi pada si ile rẹ, a ti mu ọ lara daa. Jesu Kristi ti....? [Ohun ko jade lori I erọ ti o n gba ohun silẹ]

110 Imọlẹ ti ẹ ri ninu aworan yẹn ti wa lori obinrin ti o joko lẹyin lẹyin lọhun yẹn. Gba mi gbọ pe mo jẹ wolii Rẹ, arabinrin. O n gba adura fun ọkọ rẹ, ti o wa ni ẹnu ikú ni Ile Iwosan Veterans. Bayi ni Oluwa wi ni yẹn. Gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ bayi, ara rẹ yoo si da. Kinni obinrin naa fi ọwọ kan?

(A ko gbọ ohun lori ẹrọ ti o n gba ohun silẹ) Bayi, ẹ sa ma gbagbọ ni ita nibẹ, ẹ rii. (A ko gbọ ohun lori ẹrọ ti o n gba ohun silẹ)

Ijamba ọkọ kan. Iwọ wa lati iha ariwa lọhun naa wa. O n gbe ni agbegbe Bedford, ni Indiana. Otitọ ni. Njẹ otitọ ni yẹn? Iwọ gbagbọ pe a wo

ọrùn rẹ san? Bi o ṣe gbagbọ, ki o ri bẹ fun ọ. Pada lọ si ile rẹ ki o si ma yin Ọlọrun logo. [A ko gbọ ohun lori ẹrọ ti a fi n gba ohun silẹ]

Oo Ọlọrun, nipa ti ọdọmọkunrin yi, ti o nja ija igagbọ, ti o duro ni iwaju Jeofa-Jire, Ebọ ti Oluwa pese, njẹ ki agbara ti o ji Jesu dide kuro ninu iboji, ki o fi ọwọ ba a ọmọkunrin yi bayi. Ẹ fun un ni ẹdun ọkan rẹ, ni orukọ Jesu Kristi. Amin.

Oluwa Jesu, mo gbe ọwọ le arabinrin mi. Ni orukọ Jesu Kristi, ki awọn oju rẹ ki o gba iwosan. Njẹ oun - ki awọn ailera rẹ ninu agọ ara rẹ ki o dopin ni orukọ Jesu Kristi. Amin.

Baba wa ọrun fun arabinrin mi Kidd kekere mo gbadura, mo gbadura Baba ọwọn ki O fun un ni okun ni ojọ ogbo rẹ, gẹgẹ bi o ti ṣe fun Naomi. Oluwa, njẹ ki a si lee le lo fun ogo Rẹ. Ẹ gba bẹẹ fun wa, baba, ni orukọ Jesu Kristi.

Bayi si arakunrin Kidd, Oluwa iku naa kọ lu u, ṣugbọn iye mu un pada wa. Ọlọrun mo gbadura ki o fun ni okun. O ti kọja ọjọ ti a yan fun. Ṣugbọn iwọ ni Ọlọrun, ṣe eyi fun ogo Rẹ gẹgẹ bi O ṣe ṣe ileri funmi ni ile-iwosan. Bayi, fun un ni okun fun ijẹri. Njẹ ki ijẹri rẹ bu jade ninu gbogbo Ipilẹ Ohio, ati ni gbogbo agbaye [A ko gbọ ohun lori ẹrọ ti a fi n gba gba ohun silẹ mọ.]

Pe Jesu wo mi san bayi.

Emi yoo gba Ọrọ Rẹ bi O ṣe sọ ọ gẹlẹ.

Ìwàásù lati ẹnu

William Marrion Branham

"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7

www.messagehub.info